# ÀKỌLÉ IṢẸ́

# ÌGBÀGBỌ́ ÀWỌN YORÙBÁ NÍPA ORÍ ÀTI ÌPÍN


**OMIDAN AWÓDEMÚRÌN YÉTÚNDÉ OLÚWABÚKỌ̀LA**

**NỌ́MBÀ ÌDÁNIMỌ̀:18032307010**

**Ẹ̀KA Ẹ̀KỌ́ ÈDÈ YORÙBÁ**


**IṢẸ́ ÀPILẸ̀KỌ TÍ A SE NÍ ẸKA ÈDÈ YORÙBÁ NÍ ILÉ ÌWÉ TAI-SOLARIN COLLEGE OF EDUCATION, OMU-IJEBU, NÍ ÌPÍNLẸ̀ ÒGÙN, LÁTI GBA ÌWÉ ẸRÍ OLÙKỌ́ ÀGBÀ (NCE).**

**OṢÙ Ọ̀WÀRÀ 2021**

# IJERISI

Mo fi ọwọ́ sí àpilẹ̀kọ yìí lẹ́yìn àyẹ̀wò fín ín fín ín pẹ̀lú àmójútó tí mo ṣe lórí iṣẹ́, àpilẹ̀kọ iṣẹ́ tí **Omidan Awodemurin Yetunde Oluwbukola** tí nọ́mbà ìdánımọ̀ rẹ̀ jẹ́ **18032307010** ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ tí àkànpọ̀ iṣẹ́ rẹ̀ jẹ́ Yorùbá /social studies gẹ́gẹ́ bí àsekágbá fún gbígba ìwé ẹ̀rí nínú èdè Yorùbá ti olùkọ́ àgbà (NCE) Nigeria certificate education ní ilé ẹ̀kọ́ Tai solarin college of education omu Ìjẹ̀bú ní ogun, mo rí i dájú pé àpilẹ̀kọ yìí pegedé.

____________________________
**ỌGBẸ́NI ADEYEMI S.R.**
**ALÁBÒÓJÚTÓ IṢẸ́ ÌWÁDÌÍ**

_______________
**DÉÈTÌ**

## ÌFIDÁNILỌ́LÁ /ÌFIPERÍ /ÌFISỌRÍ

Mo fi iṣẹ́ ìwádìí mi perí Ọlọ́run ọba, ọba àláwùrà tó dúró tì mí láti ìbẹ̀rẹ̀ ẹ̀kọ́ mi.

Bákan náà ni mo tún fi iṣẹ́ yìí se àpọ́nlé àbúrò ìyá mi àti ẹ̀gbọ́n bàbá mi onínúrere, Mrs. Jimoh ìbíyẹmí Temitope, Awodemurin Dáníẹ́lì.

Bákan náà mo tún dúpẹ́ lọ́wọ́ àwọn ẹ̀gbọ́n mi ọmọ ìyá mi onínúrere Mrs. Okekale Deborah Oluwasekemi, Awodemurin Babatunde, Ìyá ààfin Rashidat, Ìyá ààfin Nimotalai àti àwọn àbúrò mi ọ̀wọ́n.

Mo tún fi àsìkò yìí dúpẹ́ lọ́wọ́ àfẹ́sọ́nà mi Amos Damilola fún àdúrótì rẹ̀ èṣù kò ní yà wá O (Àmín), mo dúpẹ́ lọ́wọ́ gbogbo yín fún àtìleyìn ẹ fún mi láti ìbẹ̀rẹ̀ ilé ẹ̀kọ́ gíga ti olùkọ́ àgbà títí di àsìkò yìí.

Nípa owó níná àti ọ̀rọ̀ ìyànjú tí ẹ ń bá mi sọ kí Ọlọ́run bá mi tún ilé àti ọ̀nà yín náà ṣe. Mo gba àdúrà pé kí Ọlọ́run san yín ní ẹ̀san rere. (Àmín).

# ÌDÚPẸ́

Mo fi àsìkò yìí dúpẹ́ lọ́wọ́ Elédùmarè Ọba tó mọ mí tó mọ̀ mí, mo dúpẹ́ fún ohun gbogbo tí Eledumare ṣe fún mi fún okun àti agbára tí ó fún mi láti ìgbà tí mo ti bẹ̀rẹ̀ ẹ̀kọ́ mi, tí ó sì fún mi ní àlàáfíà ara títí di àsìkò yìí ọ̀rọ̀ mi tọ́pẹ́ ó ju opẹ́ lọ. Opẹ́ pàtàkì lọ́wọ́ gbogbo àwọn olùkọ́ ilé ìwé alákọ̀bẹ̀ẹ̀rẹ̀ títí dé ilé ẹ̀kọ́ gíga tí mo wà yìí, ilé ìwé Tai-Solarin college of education (TASCE), ti ìlú Ìjẹ̀bú ní ìpínlẹ̀ ògùn fún Ìmọ̀ràn wọn lórí ìdàgbàsókè ẹ̀kọ́ mi, ní Pàtàkì jùlọ ọ̀gbẹ́ni Adeyemi S.R tí wọ́n jẹ́ alámòjútó àti olùtọ́ni sọ́nà fún mi. Mo gba àdúrà pé,iwájú ni ọ̀pá ẹ̀bìtì yín yóò máa lọ, ẹ ò ní ṣubú dàánù ẹ ò ní rìn lọ́jọ́ tí ebi ń pọ̀nà, ní agbára Elédùmarè ẹ ò ní ṣòfò ẹ̀mí (Àmín).

Ọpẹ́ mi kò tún ní sàì lọ sí ọ̀dọ̀ àwọn olùkọ́ mi àtàtà tí wọ́n tó gbangba sùn lọ́yẹ́ àwọn bí i, olùkọ́ Ònanúgà C. Ó, olùkọ́ Agboọlá, Aya Oloyede A. Ó, Ìyá Ààfin Akinbode H. Ó. Mo dúpẹ́ fún ọgbọ́n ìmọ̀ àti òye tí ẹ fún mi. Ẹ ṣeun yóò máa jú yín ṣe oo.(Àmín).

Yorùbá bọ̀ wọ́n ní ọmọ tó bá gbàgbé ilé ó fi àpò ìyà kọ́. Èmi kò ní gbàgbé àwọn òbí mi tí wọ́n bí mi sílé ayé, bó tilẹ̀ jẹ́ pé wọn kò sí láyé mọ́, ìyá mi tòótọ́ Ìbídàpọ̀ Èébúdọlá abiyamọ lọ́jọ́ Ogun  le àti bàbá mi onínú ire Ọmọbọ́lájí bàbá rere kí Ọlọ́run bá mi dẹlẹ̀ fún wọn, kí Ọlọ́run bá mi tẹ́won sáfẹ́fẹ́ ire.

**ÀTẸ ÀKÓÓNÚ**


**ORÍ KÌN-ÍN-NÍ**

**1.0. Ìfáàrà**

**1.1 Àtúnbọ̀tán Ìwádìí**

**1.2 Ògbón Ìwádìí**

**1.3 Pàtàkì Iṣé Àpilèkọ̀**

**1.4 Gbèdéke àti gbígbóòrò iṣẹ́ ìwádìí**

**ORÍ KEJÌ**

**2.0 Ìfáàrà**

**2.1 Àgbéyẹ̀wò iṣẹ́ àwọn ẹni iṣáájú**

**2.2 Kín-ni Ìgbàgbó**

**2.3 Ìgbàgbó Yorùbá nípa Olódùmarè**

**2.4 Àlàyé nípa Òrí àti Ìpín**

**ORÍ KẸ́TA**

**3.O Ìfáàrà**

**3.1 Ìgbàgbó Yorùbá nípa Òrí**

**3.2 Ìgbàgbó Yorùbá nípa Òrí àti Àyànmó**

**3.3 Ipá tí Orí nkó nínú ayé ènìyàn**

**3.4 Àjọṣepọ̀ Orí, Òwọ́, Ẹsẹ̀ àti Ìgbàgbọ Yorùbá nípa wọn**

**ORÍ KẸ́RIN**

**4.0 Ìfáàrà**

**4.1 Ìgbàgbó Yorùbá nípa yiyẹ àkọsẹ̀jayẹ́ wò**

**4.2 Ohùn ẹnu ifá nípa Òrí àti Àyànmọ̀**

**4.3 Ìgbàgbó Yorùbá nínú Ìwà gégé bí Ifá ṣe wí**

**ORÍ KARÙN-ÚN**

**5.0 Ìsoníṣókí**

**5.1 Àgbàlọgbábọ̀**

**Àkójọpọ̀ Orúkọ Ìwé**

**Abẹ́nà Ìmọ̀**

# ORÍ KÌN-ÌN-ÌN

## 1.0 ÌFÁÁRÀ

### ÌPÍNLẸ̀ ÌWÁDÌÍ

Ọ̀rọ̀ àbùkù gbáà ni wí pé ìran kan jé ìran alaìgbàgbọ́ nítorí gbogbo íran ní ó ní igbàgbó nínú ohun kan tàbí òmiràn, ohun yòówù tí ènìyàn bá ní ìgbàgbọ́ nínú rẹ náà ní ó gbàgbọ́.

Àwọn júù (Jew) gbàgbọ́ nínú Jésù ni a ṣe ń pè wọ́n onígbàgbọ́ nínú jésù Kristi. Àwọn ará ilẹ̀ Mẹ́kà gbàgbọ́ nínú Ọlọ́rún nípasẹ àwon olòjíṣẹ́ rẹ̀, àwọn ará Híndíáání (Indian) gbàgbọ́ nínú Búdà ni a ṣe n pé wọ́ n ní onígbàgbọ́ nínú Olódùmarè àti àwọn irúnmọlẹ̀ óun òrìṣà tí wọ́n n ṣe onígbọ̀wọ́ rẹ̀, tẹni ṣáà ni tẹni, tàkísà ni tàátàn.

Àkiyèsí ti a ṣe ni wí pe àwọn òyìnbó amúnisìn ígbànì ka gbogbo ìran tí kò bá ti ni ìgbàgbọ́ nínú jésù kírísíti kún ìran alánígbàgbo. Ìdí rèé tí wọ́ n fi rí àwọn babańlá wa abọ̀riṣà gẹ́gẹ́ bí aláìgbàgbọ́.

Ìran onígbàgbọ́ ni ìran àwọn Yorùbá, ìgbágbọ́ kí í ṣe ohun ọ̀tun láwùjọ wọn, Yorùbá kò yá yìí lò láti inú èdè ilẹ̀ òkèèrè kan tàbí láti inú ésín ilẹ̀ okèèrè Kankan.

Ó yẹ láti mọ̀ wí pé àkánpọ̀ àfómọ́ iwájú 'i' àti ọ̀rọ̀ ìṣe ẹlẹ́là gbàgbọ́ ní ó di ìgbàgbọ́. Áwọn ọ̀rọ̀ Yorùbá mìíràn tì ó wà òwó ìtumọ̀ kan náà pẹ̀lú ìgbàgbọ́: Ìfọkàntán, Ìgbáralé, Ìgbójúlé, Igbẹ́mìílé, Ìjerìí ẹni àtì bẹ́ẹ̀ lọ.

Oriṣiríṣi ọ̀nà ni a lè gbà ṣe àfihàn ìgbàgbọ́ Yorùbá. Àwọn ẹlẹ̀sìn àjòjì pàápàá jù lọ kírísítẹ́nì áti ìsilíláàmù wí pé ìran Yorùbá kó ní ìgbàgbọ́ tàbí wọn kò gbàgbọ́ nínú ohunkóhun ṣùgbọ́n bí a bà wò ó ṣùnùkùn, à à rí í pè àìní ìmọ̀ tó nípa àṣà, ìṣẹ̀ àti ẹ̀sìn àwọn Yorùbá ní ó jẹ́ kí wọ́n sọ èyi, ṣé àwọn Yorùbá kúkú ti parí ọ̀rọ́, wọ̀n ní àlejò ni-ojú ṣùgbọ́n kò fi ríran" wón tún ní ilẹ̀ tí kò bá ti ojú ẹni ṣú òkùn kùn ibẹ̀ sọ̀rọ rìn" Èyí gan-an ni ó ṣè àwọn átọ̀hun-rin-wá tí ó pé àwọn Yorùbá ní ìran aláinigbàgbọ́.

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ẹsẹ-ifà, òwe àti àròjinlẹ̀ Yorùbá ni ó fi wón hàn gégé bí onígbàgbó áti ohun tí wón gbàgbó. Yorùbá ní igbágbọ́ nínú Olódúmaré, èyí ni ó mù ẹsẹ-ifá kan wí pé:

Ká jí ká yin Olórun

Ká sórò ká fi t Olódùmaré pẹlú

Ẹni bá sórò tí kò fi t'olódumaré pélú.

Ara ikú ló ń yá a

A dífá fún Amíná,

Tí ń ṣobìnrìn ìmále......

Yorùbá ní ìgbàgbó nínú òré imùlé. Ẹni tí a bá ní ìgbàgbó ní inú rẹ́ ni à ń pè ní òré ìmùlẹ̀, onítọ̀ún yóò jẹ́ ẹni tì a lè fi àṣírí pamọ́ sí ní ọwọ́ tí àṣírí kò sì ní ti òwó irú ẹni bé tù, Ohùn ẹni ifá kan sòrò nípa òré, ó ní:

Igbó náà yií ò jọbi a gbé bí ni

Ọ̀dán yìí ò jọbi a wo ni dagbà,

Bí a bá bùkún irin

Bi-a bá kọ́rẹ́

A máa jẹni abíni bí lọ

A dífá fún yèyé ẹni

Ẹléyií tí kò fifá han ni

A bù fún bàbá ẹni

Tí kò fifá hànniyán

Ìgbín bùrinbùrin ó bóòṣà dórèé.

Òòṣà lọ̀rẹ́ ẹ má dalẹ̀ o.

Odu-ifa òrosùn-ogbè òkè yìí ń jé kí ó yé wá pé oré màa gbe ènìyàn ju òbí àti àwon mọ̀lẹ́bi rẹ̀ lọ nígbà mìíràn.

Bákan náà Yorùbá gbàgbọ́ nínú orí, wón sí ká òrí sí òriṣà pàtàkì tì ó yẹ kí gbogbo adáríhurun máa bọ kí wón tó bọ àwọn òrìṣà mìíràn èyi ní ó mú wón máà sọ wí pé 'orí là bá bọ à bá fòrìṣà sílẹ̀, nígbà tíkú ń pa ni kí lôriṣà ń wò? Yorùbá gbà wí pé orí méji ní ènìyàn kàn ṣoṣo ń ni, àwọn náà sì orí óde (èyí tí ènìyàn lè fi ojú ri) àti orí inú (èyí kòşé é fi ojú rí, òun ni a pè ní ipín tàbí àyànmo). Yorùbá sì tún gbàgbó wí pé oríṣìí orí-inú méjì ni ó wà. Orí burúkú àti rere, irú èyí ti ènìyàn bá yàn láti ọ̀run ni yóò sọ irúfé édá tí èniyàn yóò dà láyé.

Síwájú síí, Yorùbá gbàgbó pé awáyé má kùú kàn kòsí, gbogbo ènìyàn àti ohùn ẹlẹ́mìí gbogbo ni itán yóò dé bá, wón tùn gbàgbọ́ wí pé bó ti wù ki a pé láyé tó, ó di dandan kí a pẹ́ ní ọ̀run jù bẹ́ẹ̀ lọ.

Lákòótán ohun tí Yorùbá ní ìgbàgbọ́ nínú ré kò pin síbí àwon ohùn tí a ménubà lókè yìí, ó tún kù nìbọn ń rò, a ó túbọ̀ máa ṣe àlàyé lékùn-ún réré ní iwájú.

## 1.1 ÀTÚNBỌ̀TÁN IWÁÁJÙ

Àáyá gbón ògúngbè náà gbón ààyè ń torí ògúngbè ń bèrè. Ìran Òyìnbó ń sa ipá láti jẹ́kí ìgbàgbó, àṣà àti iṣé Yorùbá parun nípa àṣà olájú àti èsin tí wón fĩ ń yi wá lágbo dà síná, àwọn ọmọ Yorùbá bíi t'émi náà ń sa ipá láti mú ògo àtijó Yorùbá bọ̀ sípò.

Ìhà tí àwùjọ Yorùbá òde òní kò ṣí áṣà àti igbàgbọ́ àwọn babańlá wa ni ó gún mi ní késé láti sisé lóri àkólé yìí. Ẹ̀sìn igbálódé àti àṣà ilé okéèrè tí jẹ kí àwon ọmọ kóòtù-o-ò-jíire sọ ìgbàgbọ́ àwọn babańlá wọn di agborin èṣí lóbè.

Èròngbà iṣẹ́ ìwádìí yìí ní látí ṣi ojú ìwòyè àwọn ènìyàn sí àwon òhun tí àwọn Yorùbá ní igbágbó nínú rè pàápàá jù lọ orí inú àti láti fí ìdí òtítọ́ múlẹ̀ lọ́rí í bí ìgbàgbọ́ wón ṣe ṣe mulẹ̀ tó nípa ipín (tí a tún lè pè ní àyànmọ́).

Iṣé iwádií yìí wùló lópòlopò fún àwọn akékóò àti àwón ódò tí ó ń bo léyìn ọla ní ilé ẹ̀kọ́ gbogbo.

Lákoótán iṣe ìwádìí yìí yóò sọrọ lórí oríṣiríṣi nǹkan tí àwọn Yorùbá ní ìgbàgbọ́ nínú ré àtí ipá tí ifá kó nínú yiyẹ irú ìpín tí ènìyàn gbé wáyé wò àti àwón atúnṣe tí a lè ṣe fún ẹni tí kò bá yàn ipín rere láti òde ọ̀run wá sí ayé.

## 1.2 ỌGBÓN ÌWÀDIÍ

Ọ̀gbọn ológbón kí í jé kí a pé àgbà ní wèrè, béè sì rèé ògbón ẹnìkan kò jọgbọ́n, èrò ẹnìkan kò térò, àwọn anìkànṣe kòṣe é ṣe iṣé ìwádií tí ó mó yán lórí.

Gégé bí àkọlé iṣe ìwàdií yìí **Ìgbàgbọ́ Yorùbá nípa orí inú àti ìpín**, kò sí bí a ṣe lè ṣe irú iṣe ìwádií yìí ní àṣeyorí lái ṣàmúlò àwọ́n ògbón ìwádìí lóriṣírịṣi.

Láti ní àbájáde iṣé ìwádìí tí ó yan rántí, oríṣiiriṣìí ogbón iwàdií ni modá. Lákóókó, mọ lọ àwón aṣáájú tí ó ti ṣe iṣé lóri orí inú àti ìpín àwọn aṣáájú bí Òjogbón Awolalu, Wande Abimbola, G.B Idowu, Fakolade Fákáyòdé àti àwón mìíràn.

Ẹni tí ẹgún bá gún lésè ló ń sé láńká láńká to alábẹ lọ, èyí ní óta mí pókán láti lọ fi ọ̀rọ̀ wá àwón àgbà onímọ̀ tí ó lè ràn mí lówó lóri àkòri yìí lọ. Lára àwon wonyií ní Olóyè Ifákóredé Adesina tí wón jé olúwo àwọn babańlá àwọn òmù Ìjèbú àti àwọn miíràn.

Ó tún kù ni ibọn ń ró, mọ tún ṣe àmúlò èrò asoromágbèsì àti téèpù tí a fi ń gba òhun silè látí mú kí iwádií yìí rọrùn kí ó sí késejárí.

Ní àfikún nípasẹ àtiṣe iṣé ìwádìí yìí ní àṣeyori mọ bèrè sí ní ka ìwé lóriṣìíriṣìí tí ó sọrọ lórí ipín àti òrí inú àwon ìwé bi i "Iwúre: Efficacious Prayers to Olódùmarè, Àwọn ojú odù Méréèrìndínlógún, ljinle ohùn ẹnu ifá, iwé mímó ifá. Ésin àkódá Olódùmarè; sixteen great peoms of ifa". Òpò ilé ìjósìn ní modé látí kó ìwádìí jọ fún àṣeyọrí isé ìwádìí yìí.

## 1.3 PÀTÀKÌ ISÉ ÀPILẸ̀KỌ YÌÍ

Ó ṣe pàtàkì, béè sì ní ó pọn dandan fún mí látí ṣe àfihàn pàtàkì iṣé ìwádìí yìí. Ìwádìí fí hàn wí pé òtító ní pé òpòlopò àwọn onímò tí ṣiṣẹ́ lórí kókó ìwádìí yìí àtí ohùn tí ó fí ará pé e: àmó síbè àṣetúnṣe isé ìwádìí kò gbọdọ dúró tírí sí ojú kàn, kí a lè tan imólè sí àwọn imò nǹkan tí ó tí di aikasí tàbí tí akùdé tí bá.

Ỏ pọn dandan láti tèsiwájú lórí ìwádìí tí àwọn onímọ̀ iṣáájú ti ṣe tí a bá fé kí ìdàgbàsóké tí ó péye bá àsà àti isé Yorùbá, ìdí rèé tí mọ fí yan akoriyii kí ó lé jé àfikún ìmọ̀ àtí ògbón lórí ìwádìí àwọn onímọ̀ isáàju.

Iṣé ìwádìí yìí yóò fún àwọn tí ó ń bọ léyìn ní ìru ni sókè láti ṣiṣe lórí irú àkólé yìí lójó wájú, nítorí ẹnìkan kò lo ilé ayé gbó, ìran kàn ń lo ìran kàn ń bọ ní ọrọ ilé ayé, bí ayé ṣe ń yi náà ni ìwádìí gbọdọ máà wáyé lóriṣìíriṣìí látí mò bóyá ohùn tí àwọn onímò iṣáájú ṣiṣe lé lórí sí wà bí wón ṣe rí nígbà náà, bóyà àyípadà tí dé bá a.

Bákan náà, iṣe àpilèkọ̀ yìí yóò dúró gégé bí ilẹ ìṣura àsà àti igbágbó Yorùbá. Ose tí àiní ìmọ mọ̀-ón-kọmo-ón-ka àti àìní akọsilẹ ṣe fún àwón babańlá wà kò kéré. Àìní akosílé ni ó jékí a sọ ọpọlọpọ igbàgbọ̀ àtí àṣà wà nù, tí ó sí dà bíi pé àwọn òpìtàn àti onímò ìgbà náà ń gbé òpó imò wọlé bí wón bá ti jásé láyé.

## 1.4 GBÈDÉKE ÀTI GBÍGBÓÒRÒ ÌṢẸ́ ÌWÁDÌÍ

Iṣé ìwádìí yìí dá lórí ìgbàgbó àwọn Yorùbá nípa òrí inú àti ìpín. A ó ṣe àlàyé tí ó lóòrin nípa ohun tí àwọn tí à ń pè ní ìgbàgbọ gan an, àlàyé gbogbo nínú ré. Bákan náà, a ó wo bí àwọn onímọ̀ se pààlà lááárín orí inú àti ipín.

Ìwádìí yìí yóò gbìyànjú láti wo akitiyan àwọn onímọ̀ isáájú nípa ohun tí orí inú àti ìpín jẹ. Yiyẹ iṣé wọn wò finífiní láti bù mu nínú omi ọgbọ́n wọn.

Síwájú síi, iṣé ìwádìí yìí yóò ṣi ojú wa sí bí èrò igbalódé, étò òsélú igbálódé, étò èsìn àtòkèèrè wá àti olajúṣe ṣe àkóbá fún àwọn Yorùbá tí ó sí ń mú wón bu ẹnu àté lu igbàgbọ́ àwọn iṣèrun wọ́n.

Lákoótán, Yorùbá bọ́ wọ́n ní bí ọwọ eku bá ṣe mọ ní ó ṣe ń fi bójú, ohun tí ènìyàn bá si dá ọwọ́ lé nígbà tí ẹni náà mọ́ọ̀ pé agbára óun kò ní lè gbé e lẹ́yin-òrẹyìn ti di àṣejú. Ìdi rèé tí mo fi ṣe ìwádìí yìí dé ibi tí agbára mi mọ, nítorí àkókò kò pọ̀ lórí iṣẹ́ ìwádìí yìí, ọwọ́ naa sí wà nínú ohun tí ó jẹ́ ki ń ṣe é níwọ̀nba pẹ̀lú. Bí ó ti-wún kí-ó ri mo gbiyànjú láti ṣe òtító nínú ṣiṣe ìwádìí náà délẹ̀, mo sì jé kí ó mọ ní ìkáwó mi kí ó má bà á gba oko àkùdà lọ nígbẹ̀yìn-gbẹ̀yìn.

# ORÍ KEJÌ

## 2.0 ÌFÁÁRÀ

Ogúnlọ́gọ̀ àwọn onímọ̀ ni wọ́n ti ṣe isẹ́ lórí iṣẹ́ àpilẹ̀kọ yìí "Àyànmọ́ àti Orí". Èyí tí a óò ṣe àgbéyẹ̀wò ìsẹ́ wọn nínú isẹ́ àpilèko yìí. Òótọ́ ọ̀rọ̀ ni pé kí a tó lè gba àwùjọ kan gẹ́gẹ́ bí ẹ̀yà, ó gbọ́dọ̀ jé èyí tó jé pé èdè wọn, ìgbàgbọ́ wọn, àti àṣà wọn jẹ́ ọ̀kan náà. Nítorí pé a kò lè ya èdè ya àwùjọ, láìsí èdè, kò lè sí àwùjọ.

Níwọ̀n igbà tí ìgbàgbọ́ ti ń ṣe atọ́nà fún àṣà àti ìṣe àwùjọ kan kò bá ara wọn mu, a kò lè pe irú àwọn ènìyàn béè ní ẹ̀yà kan.Yorùbá gẹ́gẹ́ bí èyà kan lórílè èdè Nàijíríà jé èyà kan tí ó jé pé èdè wọ́n, ìgbàgbọ́ wọn àti àṣà wọn pọ̀ ó si jẹ́ wọ́n lógún. Yorùbá lónìí kìí ṣe àyàbá ọ̀rọ̀, ọ̀rọ̀ tó ní ìtumọ̀ ni, èyà tó tún ní orírun ni pèlú. Nítorí odò kìí wá kó má ni orísun.

Yorubá bọ́ wón ní ọgbọ́n ọlọ́gbọ́n ni ènìyàn fi ń ṣe ọgbọ́n, bẹ́ẹ̀ sì ni ẹnikan kìí jé àwáde, ọ̀pọ̀ èniyàn ní ń jé jọ̀ọ́mọ̀. Yorùbá kan náà ló tún sọ pé ọgbọ́n inú ọmọdé àti ìmọ̀ràn àwọn àgbàlagbà ni wọ́n ń pè ní òpómúléró ní otùufẹ̀.

Lábẹ́ ipele yìí, a ó ṣe àyẹ̀wò iṣẹ́ àwọn ẹni ìṣáájú, oríṣiríṣi ìgbàgbọ́ Yorùbá nípa orí àti àyanmọ́.

## 2.1 AGBÉYÈWÒ IṢẸ́ ÀWỌN Ẹ̀NI ÌṢÁÁJÚ

Gẹ́gẹ́ bí ohun tí a sọ níwájú pé Ogúnlọ́gọ̀ àwọn onímọ̀ ni wọ́n ti ṣiṣẹ́ lórí ìṣẹ́ àpilẹ̀kọ yìí, "Àyànmọ́ àti Ori". Eyi ti a ṣe àgbéyẹ̀wo iṣẹ́ wọn. ṣiṣẹ́ àgbéyẹ̀wo iṣẹ́ wọn kìí ṣe láti bu ẹnu àté tàbí tàbùkù bá iṣe wọ́n, bí kìí ṣe láti ṣe àfinkún ìmọ̀ èyí tí wọ́n ti ṣe síwájú.

Ìgbàgbọ́ jé ohun tí èniyàn tàbí ọ̀pọ̀ èniyàn fi ọkàn sí wí pé yóò ṣẹlẹ̀ ní àsìkò ti wọ́n fé tàbí ti wọ́n ti yàn fún-un.

Gẹ́gẹ́ bí ohun ti ọ̀jọ̀gbọ́n G.B Ìdòwú sọ nipa orí nínú iwé wọn, wọ́n ní orí ni ó ṣe àpèjúwe bí ènìyàn ṣe rí. Bẹ́ẹ̀ sì ni òun ni ó ń gbé ènìyàn de ibi’re láyé. Bákan-náà wón tún tésíwájú nínú òrò pé orí náà ló mú ènìyàn dúró níwájú Olórun láti yan ohun tí ó fé jé láyé gégébí àyànmó tire.

Ọ̀jọ̀gbọ́n Awolalu (1973) náà ṣe àlàyé pé ori wà gẹ́gẹ́ bí ènìyàn tó máa n jà fún ni lórun ní àsìkò tí a bá fé yan fún oníkálulú gégébí àyànmò tire lórun.

Bákan náà ojogbón Gbádégeşin so pé ori wà gégébí ènìyàn tó pé, èyítí ó kúnlè síwájú Olódùmarè láti yan èyí tí ó wù ú tí Olódùmarè yóò si fi ôte lé e. Ó tún těsíwájú pé kò sí eniyan tó pé eniyan tó pé nígbàtí wọ̀n bá á yan kádárá tàbí àyànmo bí kò sí orí ló yan ohun-kóhun tí wón fé jé láyé fún won.

Ojogbon Wande Abimbola so nínú iwé won “Ojú odù mérindínlógún” pé igbàgbó ifá nípa àyànmó ni pé oníkálukú ni ó wà sayé láti ní àdéhùn tó kúnná pélú Qlórun rè, gbogbo ohun ti yóò gbélé ayê şe ni gbogbo ìgbàtí ó bá wà láyé.

Ní àkótán, ó tún těsíwájú pé orí jé òrişà kan tó máa á n tèlé ènìyàn kiri titi ojó ogbó. Òrìşà kan tí ó bikítà nípa ohun tó bá şele sí èdá láyé ni ori. Ohun ifâ ní pé ohun ti Olódùmaré bá fún èdá tàbí pé ẹbora tàbí irúmolè ni ó má ń fowó sowo po láti je ki ènìyàn yan ohun tí o fẻ jẹ̀ lásiko tỉ ajalá bá n sèdá rẹ̀.

## 2.2 KIN NI IGBAGBÓ?

Gégé bí àlàyé tí Adéoyè (1985), àwon òrò tó wà ni sàwáwù kan náà pélú igbagbo ni àwon oro miíràn bii IFOKANTÁN, IGBÓKALÉ, ÌJÉRÌÍ, IGBÁRALÉ. Oro ti otún je mo IGBÉKELÉ àti IGBÉMIÍLÉ, àti IGBÓJÚLÉ.

Abimbólá (1977) so pé láisí igbàgbo kòlè sí eni ti a le pè ní ìmùlè. Agbára yóòwú tí a bá gbàgbó, tí a lè feyinti fún ìgbàlà, ààbò lójó gbogbo àti nígbà gbogbo,

bá a kò tile lè fojú ríi. Dájúdájú, ìdi niyí ti bíbéli mímó fi ki igbàgbo ní idánilójú ohun tí à ñ retí, ijéri íohun ti a kòri (Heberu l1:1).

Ti ilé bá ká alágbára mó níleYorùbá, ó lèní kí egbé gbé òun, ó lè lo àféèri ti kò bá ní ìgbàgbó nínú ohun tí ó sà yii, kò lè jé fún-un. Bí oun fún'ra re ko tilẹ̀ ri agbára tí ó gbé e lo, ti kò si mò agbára tí ó ṣú otá rẻ lójú, o ní idánílójú nínú agbára tí ó ñ retí, ó si lè jérii pé yóò gbe oun tí oun kò bá ṣèké tàbí rú èèwo ohun tí ó gbékelé, o si jéríí pé bí oun ko tile ri agbára náà yóò jé fún óun.

Nínú èrò àwonYorùbá, ó jó wí pé igbàgbó ló sáájú, tí irètí atí ifé télé. Eni ti a bá ni igbágbó nínú rẻ ni a máa ń ní irèti ti ó fese mule sí, eni tí a bá ni igbágbó si ni a máa á féràn, tí a si máa n jérii rè dé ojú ikú.

Gégé bí àlàyé tí Adéoyé (1985) sẹ àti bí àwa náà ṣe mo, igbàgbó jé ohun tí a kò lè fi ojú ri, síbé tí a ní ìgbékĕlé nínú rè fún ìgbàlà, ipèsè àti ààbò lójó ìsòro. Yorùbá tàbí èyá míràn kò rí Olórun rí, síbe a gbópé Olórun ń bẹ. Igbàgbó ni ohun tí a mo pé yóò ṣẹlè, yálà láti inú iriri wa ni tàbí nítorí ìpàṣe eni tí ó gbó nnkan.

## 2.3 IGBÀGBÓ AWON YORÙBÁ

Kò sí bí a ó ti ro ebòló tí kò ní run ìgbé, kò sí bí a óò ti sorò lórí ìgbàgbó Yorubá tàbí àwon babańlá wa ti a kò ní ménuba ese ààrò won. Èyi ni îhà ilà-oorùn ti Odùduà ti ṣè wá ti jade wá sí agbègbè ibi ti à ń pè ní ileYorùbá lónií.

İwà, èsin, iṣesí àti àṣà ilà kíko wọn bá ti àwon irán miíràn tí ó ṣe láti agbegbè ilà-oòrùn mu. Pàtàki ohun tí a lè dìmú nínú ìgbàgbó Yorùbá ní pé èyá yii jé èyà tí ó gbà pé Olódùmarè ni Oba tí ó ju gbogbo oba lo, Oba tí ó rínú tí ó sì rode ni pelú. Wón ní ìgbàgbó wípé oun ni ó dá gbogbo ohun tí ń be lábé orun. Awon babaláwo máa ń fihán nínú oro won ti won fi mán ń dífá pé.

A mokun jalè

Bí oba ayé kò rí ẹ

Torun ń wò o.

Igbàgbo àwon babańlá wa ni pé àwon irúnmolèc àti àwon òrişà tàbí àkàndá edá wá láàrin Olórun àti wa èdá, owó rẻ tí ó dá sílé ayé, àti pé ni àtètè köşe ti Olórun dá imòràn pé e wá, e jé kí a dá èniyàn ni àwòrán ara wa, àwon tí ké síni àwọn irúnmolè bíi Obàtálá, Ògún, Eşù, Èlà àti Şàngó. Igbàgbó àwón Yorùbá nipé Olórun ni Olúwa àwọn irúmolè wònyí àti àwon àkàndá dá èyí tí ó rí bée.

Lára igbàgbóYorùbá ni pé ikú, kíi şe òpín fún èdá nítorí pé bí a bá parade láyé, ipàdé wa lódó Elédàá wa ní orun alákeji. Eyí ni ó mú àwon babańlá wa máa pa á lówe pé “ojó níí pé, ìpàdé kii jinnà eni tókú àti eni to sonù lè ri ara won he. Igbàgbó yìí náà ló mú ifá àìkú baale oro tí àwon awo máa ń dà pè báyìí pé.

Awo kií ku,
Awo kií rùn,
Awo ipa pò dà ni,
Ki awo má se dárò awo,
Bí ó pé títí,
Awo á tún ri awo he,
Nítorí pé bi awo bá papòdà
Itúńlá ni awo sáré lo
Ta ni kò sàimo pé
Ituńlá ni ilé àgbékéyin awo

Yorubá tún tesiwájú nínú igbágbo won nipa igbágbó nínú “Akúnlêyan”, won ni igbágbo pé àkúnleyan edá öhun ni ádáyébá won, eyi ni won fi máa n paá lówe pé a kúnlè a yàn-án tán, a délé ayé tán ojú ň kan wa, işębo nişoògùn bí a ti wayé pé àárí

òhun náà ni aárí. Ó jẹ̀ igbagbó àwon babańlá wa pé gbogbo edá ní ó ti bá Elédàá rẻ dá májèmú kí wón tó wá sílé ayé.

Bákan náà èwè, a tún lè rí àpeçre igbàgbó wonyí nínú ìgbésí ayé Elà eni ti àwon igbagbó ń pè ní Jésù ti gbogbo èniyàn mo pé Olộrun ni ó ti yan işé àti ìgbésí tí yóò lo lórí ayé..

Ni àkótán, igbágbóYorùbá kòsé é ménubá tán nítori iran Yorùbá pò jáňtirerę lórile ayé.

## 2.4 IGBÀGBÓ YORÙBÁ NÍPA OLÓDUMARÉ

Ojú kèfèrí póńbélé tí ò ní ìmo Olórun ni awon elésin Kirisiténi àti elésin isiláàmù fi ń wo àwonYorùba nígbàtí won gbé èsin ti won wá síleYorùbá. Eyi ni ó mú kí ojogbon kan tí orúko re ń jé **“TregbonRopérs”** so pé àwon adúláwo kò le mò nípa Olorun nítorí pé opolo won kéré ju ki wó n ní irú imo nlá béè. Amó tí a bá dejú tí a sì rímú, a ó gbà pé láti ibèrè ayéni Yorubá ti mo nípa Olórun.

Ní odo àwonYorubá, itumo Olórun ni Olú Orun iyen ni pé oun ni ó ni orun tàbí wipe Oba Orun ni. Orúko ti àwonYorùbá tun máa á pé Olorun ni Olúwa, èyí tí ó túmo sí eni tí ó ni àwa èniyan. Yorùbá gbà pé Olórun ni Elédàá-eni tí ó dá ohun gbogbo, Yorùbá tún máa n pé Olorun ni Olodumare. Opolopo àwon ojogbón ló ti gbìyànjú láti se àtúpale oro yii “Olódùmare”.

Idowu  (1962-1963) so pé Olódùmaré jé oruko tí ó lódií-igbin. Ó gbà pé àtúpalè rè kò rorun nítorí pé ó ní látí je pé orúko àti jó ni. Ó şàlàyé pé óní ohun tí á á n wò kí a tó somolórúko lópò igbà, gbólóhùn kan tí ó ní orúko máa n jé. Bákan náà ni ó gbà pé orúko yìí “OLÓDUMARÈ,” je èyí tí rorùn láti tú palę.

Felá Sówándé so pé, àtúpale Olódùmarè ni Olódù ọmọ Àrè . Ó gbà pé olódù ni eni tí ó tóbi lópolopo, tí kií se omo enikan tàbí ọmọ tí a mó. Aláiní iyá, baba, tàbí

ẹbí ni Yorùbá ń pè ní Àrè . Thompson (1997) gbà pé eni ńlá yìí kò ní iyá tàbí bàbá. Ó sá à wà fún Ara rẻ tàbí pé òun fún'ra rè ló dá ara rẻ.

Nínú igbiyànjú láti fi hàn wí péYorùbá ni igbàgbó nínú Olórun, e je kí á şe àgbéyéwò àwọn kókó wonyi bí ó şe hàn nínú ìwádií àwón omoràn bii:

Awólalu (1979), Thompson (1977), Idowu (1962), Adéoyè C.L (2010) àti àwon miíràn ti èrò won kò fi béè jinnà tàbí yapa si ara won.

İgbàgbo Yorùbá ni pé Olórun ló dá ayé tó dá àwon èdá inú rẻ, àtí pé gbogbo àwa edá wá sínú rẻ bii eni to lo jabo. Odú ifá Oyèkú Mogbẻ jérií si èyi. Ifá náà lo lọ báyii;

Ayé lojà, orun nilé,

A díá fún Olódùmarè baba atáyé matu

Bée délé ayé, béẹ gbàgbé orun

Ayé loja, orun nilé èrò,

E o jíyin, ẹ ó jábó.

Ohun ti e rí

Bí ifá náà ti lo ni pé Olódùmarè ni ó tẹ ile ayé do. A gbà wí pé bí êniyàn ń bá dá oja kan, òun náà ni yóò tèé dó. Òun náà ló sì dá àwón ènìyàn sí bè ki wón si tún padà wá láti wá jábó.

Léyin náà, àwon Yorùbá gbà wí pé wón ní láti máa fi orúko Qlórun sí ohunkohun ti wón bá ń se láyé, nítorí pé bi kò bá sí Olórun àbá édá kan kan kò lè şe. Odù ifá ìwòri ogbè náà fi èyí hàn pé;

Olorun İbà

Bi edię bá mumi, á fibà f'Ólórun

A díá fún àdába sísi ti ń rabé àká

Òyagbe lo ó yín sí

Bí o sí t'Olorun,  àbá èdá ò le şe,

Olórun İbà

B'édiye bá mumi a fibà f'Ólórun.

Eyi fi hàn pé Yorúbá gba pe Olórun wà àti pé oun lo ni gbogbo àbá ti àwon bá ń dá.

Yorùbá gbàgbo wí pé Olorun kan şoso ni ó wà, Olorun yií kò bimo, bée si ni enikan kò bi, wón gbàgbó pé oun ni Oba, idí niyí tí won fi maa ń so wí pé;

Olórun nikan lo ba, oba bíi irú Olorun kò sí iru Olorun ko si. Wón gbà pé arínú-róde ni, kò sí ohun tí èniyàn lè yo se ti ojú u re ko tó. Idi niyi ti wó n fi máa ń so pé ohun tí ó pamó, ojú Olórun tó o, Arínú-róde Olùmoràn okàn tí ó fihàn wá wipe ìwà ti èdá bắ wù jade nikan kó ni ojú Olórun tó, ó tún mo èrò okàn kí èdá tó fi hùwà jáde.

C.L. Adéoyé(2010) so pé igbàgbó àwon Yorùbá ní pa Olórun nipé àwon irúnmole àti àwon òrişà tàbí Àkàndá èdá wà lááárín Olórun àti àwa ĕdá owó o rẻ tí ó dá sílé ayé àti pé ní àtètèkóşe tí Olórun dá imòràn pé e wá, ę je kí á dé ènìyàn ni àwòrán ara wa, àwon tí ó ké sí ni àwon irúnmolè, Olorun yii ni Olúwa àwon irúmolę wonyí àti àkàndá èdá tí ó di òrìşà, tí ó fi jé pé okánlénírinwó òrisà ni ó wà ni ileYorùbá.

Gégé bi oba àwon oba àti oludari ayé àti òrun,   Elédàá ni ipò rẻ ga jùlo igbàgbo àwonYorùbá nipé àwọn irúnmolè àti òrişà wonyi ni àwon eni tí a lè lò bii

alágbàwi àti onilàjà wa lódò Elédàá bí a bá ní ohun tí a fé toro, tí a bá ní èrùndùn tàbí ohunkóhun láti bèèrê lówó Aláwùràbí.

## 2.5 ALÀYÉ NÍPA ORÍ ÀTI İPÍN

Orişirişi ītán atenu dệnu tí ó ti wayé látí enu àwọn onímò pàápàá juló éyi ti a kà nípa ori àti ìpín. Ori ni ó şe àpèjúwe bí èniyàn şe rí, bée si ni òun ni ó n gbé èniyàn dé ibi rere láyé. Bákan-náà òun ló n mú èniyàn dúró níwájú Olórun láti yan ohun tí ó féjéláyégégébíiipíntirẹoríeniló á jà fun ni gége bi èniyan bá se yàn-án láti orun. Ojogbon C.L. Adeoye (2010), so nínú ìwé rè pé oríşirisi onà méjì tàbí méta ni èniyàn máa ń gbà yan ipin ti won nípaşè orí. Elòmíràn a máa kúnle yan tire, nígbà tí elòmíràn a máa kunle gba tirẻ. Ó ní tí a bá ń sorò orí tàbí ipín, kosí kí a má ménuba àwon wonyi nítorí kò fé è sí ìyàtò láàrin won, bëe si ni won jo ń ṣisé pò ni. Awon oro náà nì wonyí.

i. Akúnlegbá
ii. Akúnleyan
iii. Kádárá
iv. Akosile

AwonYorubá pón ori lé kojá ohun ti àwon èniyàn ń pè é nílé opolo tí ň dari ara. Won so àfihan Olódùmarè gégé bí olórí àwon òrişà tó ku. Awon òrişà tàbí irunmole wonyí ló mán n se iránsé fun Olódùmarè. Orúko miíràn tí àwonYorùbá tún máa ń pe Olódùmarè ni oba orun, Olú-iwà. Ifá pàápiá pa á láse fún irúnmolé láti bu olá, owo tó tófún ori, eni ti n şe Olódùmarè. A rí àjùlo orí nínú oro tí àwonYorùbá máa n sọ pé;

Orí ló dá ní, enikan ò dóri o
Orí eni lelédàá eni.

A ó ri pé òrò yìí şe àfihàn ori gégé bii ipò adarí nínú ètò ijoba ní ileYorubá. Bi apeerẹ. Agboolé kokan ló máa ń ní olóri, béè sini a tún máa ń ni olóri Ádúgbò, tàbí Baálẹ.

Oro ti olóri agboolé ò bá ti lè yanjú ni wón máa ń gbé lo sí odo olórí àdúgbò. Oro tí olórí àdúgbò Olórítún tàbí Baálè ò bá ti lè yanjú ni wón máa ń gbé lo sí odo oba (eni ti won gbà gégé bíi igbákeji òrişà) pelú ìrànlówo àwọn ijòyè tàbí àwon agbàągbà.

Ki àfiwé oké yìí lè yé wa dáadáa, ẹ má jẹ̀ẹ̀ kí a gbàgbé péYorùbá gbàgbo pé Obàtálá ni eni ti Olórun fún ní àşẹ láti máa mo ère ènìyàn tí oun Olódùmarè yóò sì máa mí èémí si won nínú ki wón lè di alààyè.

Nínú aláboyún ni igbésè ìşèdá yìí ti máa ń wáyé, ó máa ń tó bíi oşù mésàn-án kí ó tó gbó. Şùgbón ki won tó bímo náà sáyé, Yorùbá gbàgbó pé ọmọ náà yóò kókó dé odò Àjàlámopín eni ti ń şe Amòkòkò orun láti lo yan ori-inú lára àwọn ori ti won ti mo silè. Gbogbo àwon ori wonyi ni Olódùmare fún ni agbára láti lè gbé nnkan şe láyé. Èyíkéyii ti oníkáluku bá ti yan ni ipin rẻ láyé. Ìdí rẻ é ti Yorùbá fi máa n so pé "Ori-Lonise"

Yorùbá ní igbàgbọ̀ nínú àyanmó, wón gbàgbo pé ohun kóhun tí eniyan bá dà láyé máa n ní í se pèlú ipín tó yàn láti orun. Ní ibi ti àwon kan ti yan ipin olówó, níbé ni àwon miíràn ti yan ipín òtòsi. Bákan-náà ni àwọn kan yan emí gígùn,tí àwon kan sì yan iku àitójó.

Ipin yii ni ó n şe atóka áşeyori tàbí ijákulé éniyàn. Bí enikan bá di olówó, àwon Yorùbá a wipe ipin ti è ni, bée sini bí enikan bá kú léwe, wón á pé bó ti yàn-án láti òrun wá ni. Eyi fi hàn pé gbogbo làálàá ènìyàn láyé, yálà ó já sí rere tàbí búburú ní I şe pèlú ìpín rè láti orun. Ìdi niyií ti Yorùbá fi máa ń wí pé;

A kúnlè a yàn-án,
A dáyé tán,
Ojú ń kán ni.

Níle Yorùbá won fún àyànmó ní orişirişi orúko, òun náà ni à ń pè ní ipín kádárá tàbí iponri. Yorùbá gbà pé àmì àyànmo ni orí tí oníkálukú gbé wá láti orun. Nitori igbàgboYorùbá nípa ori, wón máa ń so pé:

Eni tó gbon

Orí è ló ní ó gbón

Eniyàn ti o gbón

Ori rẻ loni o gò

Ori la fi ń méran láwo

Orişà bíbo ni esin Yorùbá dá lé lórí nitori won gbàgbó pé àwón òrişà wonyi dúró gégé bii aşojú fún Olódùmarè, eni ti won gbàgbó pó tóbi ju eni tí àwon gégé bi èniyàn lè dá to lo. Síběsíbé, Olódùmarè n fi ori inú bá eniköökan lò ní gbogbo ojó ayé wa.

Nitori èyi ni àwon agbàlagbà láyé àti jó fi máa n ní ibi ibo fün ori inú won eyi ti à n pè ní “Ibori”. Iborî yii ni wón ó kóko jí bo pělú ébùn àti àdúrà kí wón tówá kojú sí òrişà idílé. Ìdí rè é tí won fi máa n so pé kò sú òrìşà tí n dáni gbè léyin orí eni. (Abimbola 1971)

Awon òrişà yii paápàá ní orí ti won ti won máa ń bo èyí tó túmo sí pé òrisa kankan ò lè ran enikéni lówo jubí Olódùmarẻ bá ti yan fun lo.

Ni òtító àwon Yorùbá pón orí-ode tí à ń fojú rí yii lé, şùgbón síbé wó n gbàgbó pé igbá kodoro tí a fi ń bo orí inú ló jé. Nítorí pé Yorùbá gbàgbó pé ori inú àti orí-òde gbodo wà ní irépo ni wón şe máa ń şàdúrà pé ki orí inú má ba tòde mi je.

Orunmilà ni alágbàwí àwon ibo to kù, óun náà ló máa ň so ohun ti ori oníkálukú bá ń fé fun-un. Awon Yorùbá máa ń pè é ní Elérií ipín (Witness of man's

choice of destiny) Yorùbá gbàgbo pé orúnmìlà wá níbě nígbà ti enikookan ń yan ipin rẻ lorun, idí nìyí tí ó fi rọrùn fún-un láti lè so ohun tí ori enikookan bá fé nígbàtí wón bá ń bèèrè lówó ifá.

Niwon igbà tí onikálukú tí yan ipin ti rè láti orun, ó pon dandan fún eniköökan láti máa bèèrè ohun tí orí rè fé àti ohun tí orí rè kò fé lénu ifa. Nipase èyí, oníkálukú yóò lè rin ni onà tí a yà silè fùn-un láti orun lái şi ona yà. Idi niyí tí àwonYorùbá fi gbàgbó pé ifá ń kó ipa tó şe pàtàki nínú ayé omo adáríhurun.

A lè so pé nígbàkúùgbà tí enikan bá lo se iwádií lénu ifá ohun tí ó n se ni pé ó fé mo ohun tí orí òun fé, nítorí ifá ni yóò gbé imoràn àwon irúnmolè àti ori to Olùbéèrè lọ. Òun nááyóò gbé ebo olùbéèrè lo si odò orí àti àwon irunmole.

Ti àwon irúnmole ni láti sin orí dé ibi àyànmó láyé. Ohunkóhun tí orí éniyàn bá sì ti ko, kò sí irúnmolè pàápàá ni ori ti wón tí ó máa n dári won ni igbà gbogbo. Bí àwa ènìyàn adárúhuwun ni àwon irúnmolè náà şe máa ń bèèrè ohun ti ori won fé lówo ifá tàbí irOrúnmìlà pàápàá bèèrè ohun ti ori re fé lowo ifa. Okan lára ifá tó fi hàn pé Orúnmìlà bèèrè ohun ti orí rè fé , lowo ifá niyi:

> Ikú, àrùn, ofo égbá, èşè,
>
> Gbogbo won ni ń yo orunmila wò,
>
> Won ń wí pé ojó kan,
>
> Ni won o pa á
>
> Ní Òrúnmìlà bá gbé òkè,
>
> Oporu re kale
>
> Nnkan lò dérù ba orúnmìlà
>
> Lổ bá wá lễ

Ó bi oké ìporu re léèrè wò.

Bí ori se pàtàki tó nínú igbágboYorùbá, opolopo ese ifá yìí ni ó jé pé inú Ögúndáméji ló wópò jù lọ. Ini ori nínú ese ifá se àfihän igbàgbó Yorùbá nípa ori ni kedere.

Nínú iwe ohun enu ifá ti àgbájopo àwon ojogbón jùmo se ní a ti rí éwi ti ó soro nipa orí tí akolé ré á je orí. Åpeerę, Olá Orí – Apeerę Olá atàkàrà ileke,

Láisí àní-ání, orí ni òrişà tótò,

Kösi orisa kan ti n dáni gbĕ léyin ori eni

Bi o se jé pé atókun nírí daníèégún.

Ori eja leja fi ń labú.

Bée gégé ni Yorübá ní igbagbo pé ori ló n se amonà edá láyé lode isaluaye.

Ori tooto tí n bá ni roja, bá nipadá

Elédáa eni ni ori jé,

Ayanmó eni ni ori

Orí tó máa n gbeni kii wi fún ni

Nigbaküügbà bí ojó, ti n yo

Won a máa mú eéji kún eta.

Wón á lo béèrè lowo ifa pe

Kin ni ori awon f e

N je irinājo ti mo fệ rin yii

Se yoo gbe mi

Se mo lè mú orí délé bí?

Yorubá bo, won ní àgbȧ do tá lớ jà, njé o béèrè lówo orí re kí ó tó gbegba agbado. Gbogbo ebo ti wón bá si rú, won fi n bo ori won, ki ori lè je ki ohun ti won fé dáwo lé já si rere.

Igbagbo awon Yorùbá ni wípe ti èniyàn bá fé dáwo lé nnkan ńlá kan, bii ki a fe lo si ile-oko tàbí gbé iyàwó tàbí pé a fé kó ílé, wọn yóò se ayewó lowo ori ki elédáá má se jé ki won şiyàn täbí şigbé. Eyi ni ó mú ewi yil bayii wi pé.

Ayé di odiju, wón n pè è ní olájú

A o fimò se ti àwon alálé mó.

A o fimò şe ti işèşe,

A o fimò şe ti àwon babańlá wa mó,

A kií bèèrè onà ká tó rájó,

Ayé wá dayé èyi jẹ, èyí ò jẹ,

A fimàdò wé kan lódo,

Ayé dayé bóşe gbà.

Títóbi orí tàbí kékeré ori ko ni a le fi mo irúfé orí tí edá gbé wá ilé ayé èyí ló mú àwon babańlá wa máa to ifá lo nígbàkúúgbà. Yorùbá gbagbó pé örúnmìlà ni elérii îpîn (Witness of Destiny), oun nikan ni òrişà tí ó yan irúfé ori ti enikookan gbé wá ilé ayé.

Nínú odu mímo, Òsá méjì, ifá ní;

Ori burúkú kii wú túlu-tuúlú,

A kií dá ese asiwerè mo lójú onà

A díá fún mobomu ti ň şe obinrin Ògún,

Ori tí ó joba lola, enikan ò mo,

Ki toko-taya ó má pe ara won ni wèrè mo.

Bi a bá wo esȩ ifá yií, a ó rí àrídájú idi ti àwon babańlá wa şe difá. Një edá ayé kan lè so pàtó pé orí rè tàbí orí burúkú máa n rí bákan.

Bí a bá kó orişirişi esè jo, njé èdá kan láyé lè ya esè asiwèrè sóto? Ifá nikan ni omoràn tí ó mọ oyún inú igbín, Ogbon fi bȩ nínú Òrúnmìlà, oun ni amáyégún.

Odùdù tí n di ori îlémère,

Ki ori ilémère má şe bajé,

A tún orí ti kò sun won se.

Nígbàti a kúnle tí a yan èdá ìpín lódo Àjàlá, Orumilà nikan ni ó wà ni bé tó şe elérií ipin irúfé orí tí oníkáluku yàn wá sayé láti òde orun. Oun nikan ni Olorun fún láşe láti mo ipín èdá.

**ORÍ KẸ́TA**

## 3.0 ÌFÁÁRÀ

Orí tí à ń sọ̀rọ̀ rẹ̀ yìí orí inú, kìí ṣe orí tòde tí à ń gbé ká à kiri. Lẹ́yìn tí Ọlọ́run bá ti fi èmí fún èdá tán nígbà tí wọ́n bá mọ ó tán, ẹ̀dá náà yóò wá kúnlẹ̀ sí iwájú Ọlọ́run láti bá Ọlọ́run dá májẹ̀mú ohun tí yóò jé bó bá dé ayé. Ìpín tàbí àdéhùn tí édá náà bá ṣe pèlú Ọlọ́run ni àyànmọ́ tàbí kádàrá. Édá tí ó ṣe àdéhùn tàbí tó Yàn ìpín lódò Ọlọ́run yìí ni à ń pè ni Elédàá eni.

Orí tí a gbé lórí ni ó dúró gégé bíi Elédàá ẹni bí ohun àfojúrí. Nítorí náà bí a bá í ṣorò orí, oro Elédàá ẹni ni à à sọ. Èyí ló fi jé pé bí obìnrin bá fé lọ́ di irun orí rè, á so pé òun fé lo tún Elédàá òun ṣe. Orí ẹni tàbí Elédàá ẹni kìí padà lẹ́yìn ẹni, bí aráyé tàbí òrịṣà tilè padà léyin ẹni, òhun ni a fi máa ń sọ pé;

Orí àtètèníran,
Àtètè gbéni ku fóòsà,
Òṣikà ò fẹ́ ká rẹrù ká sọ̀
Orí ẹni ló ń ṣó ni
Orí ẹni làwúre ẹni
Orí ẹni níí jẹ̀ jewé lọ,,
Oríja ju oògùn.

Nítorí náà orí jé pàtàki òrịṣà tí ẹni kòòkan ń bọ nílẹ̀ Yorùbá ìdí nìyí tí Yorùbá fi máa ń bọ orí ara wọn nígbà ti wọ́n bá ń ṣe orí ire tàbí tí wón bá ń torò ire kàn, wọn tún gbàgbọ́ pé orí ẹni ní ń sin ni débi ire.

Àwọn Yorùbá ka orí sí púpo pé òun ló dágba ju ló nínú gbogbo ará ìyókù. Òun ló kòkò délé ayé kí orùn tó té le, ká tó wá kan esẹ̀. Nínú gbogbo ará láti óde òrun ni a kà orí si nǹkan pàtàki. Ọ̀tọ̀ ni a dá òun nìkan mọ̀ gédégbé tí a sì fi dá kàn sóo. Ìdí nìyí tí àwọn náà fi ka orí kún láyé. Ṣé ẹni tó bá jógàá ni à ń pè ni olórí.

Bí nǹkan bá kànrángídá tán, tí ó ti lowo òrìṣà, à fi kí a bẹ Orí ẹní. Orí Àpéré, a si ni wáyé, orí oníròó tíí ro mo ni bí aṣo. Idi niyí tí a fi ń bo orí tí a bá yọ nínú ẹwù kàn, kí àpárí inú má ba tóde ẹni je. Kò si sí ákókò kan pátó tàbí odún kan pàtó láti bo orí. Ìgbá tí ewu bá ti wu ènìyàn tó si bó nínú re ni à ń bo orí.

Láyé àtijó, pàápàá òde òní nítorí a sì rí àwọn kan tó sì gbàgbó nínú rè di òní olónií pé tí a bá ṣèsè bí ọmọ tuntun a o wádií lówo ifá pé irú orí wo ní omo náà mú wá sáyé èyí ni à ń pè ni ese ń tayé tàbí ifesètẹpón omo. Ibé ni a ó ti rí irú eni tàbí nńkan ti oo náà yóò dà lójó ayé re. Bákan náà, ni a ri àwọn aláwo wón máa ń mo ìponrí ará wọn. Eyi ni gbogbo bí ayé àwon yóò ti rí ní ayé. Ti ènìyàn bá sì fé ta esè àgèrè, wọn le ki iponrí rè fún-un èyí tó le ṣe àtúnṣe ayé rè tàbí tí ó lè bà á je bí wón bá ti fé kì ó rí fún-un.

Láti fi bí orí ṣe ṣe pàtàkì sí hàn, àwon onísé onà máa ń mo kin ní kàn bii súgúdú, wón á to owó-ero (owó ẹyọ) mó on lára, wón a gbé e sínú igbá adému kan lókàn-o-kàn ilé níyàrá, a ó sì máa pè è bí nnkan bá fé dijú tàbí kí wón bò ó, wọn á si máa kọrin pé:

> Mo dé lé orí
> Mo tẹramọ́ iyán Í je
> Nǹkan Òsìnsìn ni n á máa forí mi

Atéwọ́ nìkan ní wón máa ń pa si orin yìí, wón kìí lu ilù si, wón si máa ń jó síi. Ṣùgbón ṣá òhun tó ń dùn ni ló ń pò lorò ẹni. Gégé bi Oluwádií, ohun tó jemí lógún nínú ìwádií yìí ni pé orin inú tí àwọn Yorùbá fi máa ń so pé ki “Ori-inú má ba tòde ẹni jè.” Gégé bi ipín tàbí àyànmó náà ní tí ori ènìyàn bá burú, tí ènìyàn bá ri àṣeti, ofo, iṣubú àti ìyà ni yóò máa jé tiré nígbà gbogbo. Bí orí ènìyàn bá si dára ohun gbogbo tó bá dáwólé, rere ni yóò má yorí sí, olùrànlówo kó ni won-on, òfo kò ní ṣe é, béè ni àmúbó àti àṣeti kò ní je tirẹ̀.

## 3.1 ÌGBÀGBỌ́ YORÙBÁ NÍPA ORÍ

Àwọn Yorùbá gbàgbó pé yíyàn ni a máa ń yan orí láti òde òrun wá. Òrìṣàńlá tó ń dá ènìyàn tó ń dá ojú, imú, àti ẹnu, ṣùgbón Olódùmarè ló n fún ènìyàn ní èmí, àwọn ẹlòmíràn ń so pé Ògún ló ń ro egúngún ènìyàn.

Wánde Abímbolá (1997), sọ pé odo Alajá ni a ti ń yan ori-inú, orí-inú yìí ló dúró fún àyànmó tàbí ìpín àwa èdá. Odù Ogbègúndá ló pitàn bí èniyàn ṣe yàn orí lórun. Ọwó oníkálukú ní ó fi gbé orí tó bá wù ú. Ṣùgbón nítorí pé omàti àtí onigbèsè ní Ajàlá, alámọ̀ tí ó mó orí púpò nínú àwon orí burúkú. Òmíràn tóbi lásán, ṣùgbón tí ó jé wí pé àjàlá kò sùn jiná. Béè náà si ni àwọn orí tí Ajàlá mọ dáadáa tí ó sì tún sún jiná wà. Ẹni tí ó bá fi ọwọ ará rẹ gbé èyí tí ó fọ́ sára tàbí ti wọn sun jinná ye kó mà dájú pé kí òun ó tí rìn dé òde ayé, orí burúkú náà á ti yìnrìn dànù tán lóná nígbà ti ojo bá dé. Ṣùgbón ojo àtí òòrùn kò ran orí tí Ajàlá bá sun jiná wá láti öde grun. Ení tí ó bá yan orí réré nílé àjàlá, bó bá délé ayé tán ó di kí ó más rí ṣe, kí ó máa kólé-mólé, kí ó máa fàgbàlà kàntà, irú eni béè ló ń jèrè òtítí baba ajé.

Eni tí ó ba yan orí burúkú, tó bá ṣiṣé kò jèrè kankan. Irètí kan náà tí ó wà fún irú eni ni kí ó máa bà á ru orí burúkú tí ó gbé títí yóò fi pada so ó di déédéé èyí tí ó gbé kùrò lóde orun. Nígbà náà ni eni tí ó ni orí náà yóò tó ó máa ri ṣe.

Idowu (1962) se ìwòye pé:

> In the belief of the Yorùbá
> It is this orí that rules,
> Controls and guides the life,
> And activities of the person

Ẹ̀yí ni wí pé nínú erò àti ìgbàgbó, orí inú ló ń ṣe àkóso tó si ń dará ìgbésí ayé àti ìṣèdá ènìyàn. Yorùbá gbàgbó wí pé ori ni àwo èyá ara yoóku tẹ̀lé wáyé tí orí bá si ti kúrò, ara tókù kò wúlò mó. Bí ó ti jé pé orí ti òde yìí ló jé alákòóso igbésí ayé

ẹnikọ̀ọ̀kàn, tí a bá wo bí orí e ṣe pàtàki tó lára èdá, a ó lè fojú inú wo pàtàki orí inú nínú ìgbésí ayé èdá. Gégé bí àpeere, orí ni a lè fi dá èniyàn mò, tí ó bá kú òkútú ara, àyàfi àmì tí a bá ti mo èniyan kan mó télè ni a lè fi dá a mo. Bóyá ìdí tilè niyí tí àwọn Yorùbá fi máa ń wòye wí pé;

> Bí ò sí àtànpákò, bí ilàgbà lówó rí,
> Bí ò sí orí, ara adàbí òkútú igi

Olúdáre (1982), ṣàlàyé kan wí pé, orí je pàtàki òrìṣà ti ẹnìkọ̀ọ̀kan bọ orí ara wọn nígbà ti won bá ṣe oríire tàbí tí wón bá ń tọrọ ire kàn. Wọn tún gbàgbó pé orí eni ni n sini dé'bi ire. Béè náà ni àwon Yorùbá gbà pé ohunkóhun tí a ó bá dà lóde ayé yìí, àti yàn-án láti òde òrun. A lè yan réré tàbí búburú. Èyí ni pé ó le jé àbò tàbí ako. Bí ó bá jé àbò, iségun àti ayọ ní òrò olúwa rè yoò máa já sí nígbà gbogbo. Bi ó bá jé ako ni, ofo, àṣeti àti iṣubú ni yóò máa bá onítoún nígbà gbogbo.

Bí ènìyàn bá dé ibi iṣé tó tètè ní ìgbéga tó si di ògá àwọn tó bá níbẹ̀. Àwọn Yorùbá á ní orí rè ni, wọn á ní "Ayànmó rè ni". Bí ọkọ kan bá sí subú lójú onà tí gbogbo èniyàn kò fi ara pa ṣùgbón tí enikan ṣoṣo wá kú, wón á ni Àyànmó ẹni tó kú náà ni. Tàlú tí gbogbo ènìyàn bá ń ṣe kínní kan ti wón ń mú jè, to wá kan enikan tó di oràn mó-on lówo àwon, aráye á ní orí rè ló le, wón a ni Àyànmó tirè ni. Bí ẹnìkan bá ré wa jè, a gbàgbó pé ori wa á bìí léèrè, ìyen ni pé orí wa á gbè wá níjà, ori ẹni ni kìí jé ki iyà jẹni gbé.

O tè síwájú pé orí rere lè di orí burúkú, ohun tí ó lè fa èyì ni ìwà. Bí iwà ènìyàn ko bá dára, ó lé bá orí rere rè jé. Èyi ni wón ń pè ní, orí-inú ba tòde je, ṣùgbón ó fiwà burúkú bá ori rere rè je. Bi àfiwé, ènìyàn lè ní orí ire kí ó máa rí iṣé ńlańlá èyí tí ó ní owó lórí nígbà gbogbo ṣùgbon kó jé pé bó bá ń wo ise tan ló máa bá gbogbo ògá àti àwon òṣiṣé jà, tí wón bá dá a dúró, èyi ni orí inú, tí ó ba tí òde jé. Ṣùgbón bí èyí bá á rí béè, omo aráyé á tún so pé Áyanmó rè ni. Orò Àyànmó yìí le tó bée tó jé pé kò fé jé kí elòmíràn ṣiṣé tàbí kó là kàkà tó bí ó yẹ nitorí won igbàgbo wí pé òrun tí mo eni

tó ma là, ẹni tí ó lá láyé ti yàn-an láti orun, o ṣiṣe kò ṣiṣẹ. Ẹní tó bá si máa kúṣèé, bó tí wù kó ṣiṣé tó, kò lè là. Òhun ni àwọn Yorùbá ṣe máa ń so pé.

Kirákità kò dolà,
Ká ṣiṣé bí erú kò da nǹkan
Orí ló ma iṣé àṣelà eni.

Gégé bi ìgbàgbọ́ Yorùbá, ó dà bí ẹni pé orí mo nípa Ayànmó tàbí pé ori ẹni máa ń tó ni sónà iré, tàbí kó gbé ni sínú ibi. Òhun ni a ṣe máa ń ṣádúrà pé:

Orí mi gbére pàdé mi

Ohun míràn tó tún ṣe pàtàkì nípa orí ni pé, kò ṣeéṣe fún àwa èdá láti mo orí tó burú yàtò sí orí rere. A kò mo orí tí yóò lówó tàbí orí ti yóò jiyà, Ìdí niyi tí a fi máa ń so pé:

Ànjọ̀ọ́rìn a ò mọrí olówó
Edùmàrè ló morí ọlolálágbìgbó

Afolábí Olábíntán (1986), ṣàlàyé pé nígbà tí a mo orí tán, a ṣe ètùtù nípa rè, ohun tí a sì fi ṣe ètùtù náà ni iyán, obè ègúsí, obi, àbàtà, àgbọn oníkótò. Eyi si ni òriṣàńlá pa á láṣè pé kí á máa fibo orí. Fún ọbẹ elégùúsí yìí, kí á gún yárí, kí á fibo orí. A ó máa wá korin pé:

Orí mi má mà jẹ́ kọ́ ya
Ewé kókò la fi sànù ọ̀jẹ̀
Orí mí má mà já kó ya.
Orí ẹni ni alábàárò ẹni
Orí ẹní ní í yọni nínú ewu.

Bí nnkan bá kánrángídá tán, tí ó ti lowo òriṣà ifá nínú, àfi kí á bẹ orí ẹni.

Gégé bí àlàyé tí (Íjàdù1907), Ṣówándí àti àjànàkú (1969) tóka sí lo bayii;

Olódùmarè ni Òun ń fé eni ti yóò joba,
Òun pa obì oòrè nínú àwọn irúnmolè,
Ogun dé ó paáti, Ó jókòó síbẹ̀,
Gbogbo irúmolè dé lóòókán,
Wón pa obì ọtí , wón jóokó,
Gbogbo irúnmolè wón ń lérí de eni,
Ti yóò wa pa obi tí àwon ti pa ti,
Níkẹyìn ni wón ri ori tí ó so,
Ó ń yi pọ gbírígbiri,
Ó dé, ó mú obì kan, ó pa á ariwo ta,
Olódùmarè ní orí ìwo náà lo tó,
Obi oòrè yìí pa lódtóo,
Béẹ̀ ni gbogbo irúnmolè bère,
Ṣí ní jupò pelú owú jíjẹ,
Orí ló dá gbogbo won lóòókán,
Ó dá plóta sílé Ádó
Ó dá Erinmi sóde owo
Ó dá pépé sóde Asún.

Ohun tí àyolò yìí á tóka si ni bí orí ṣe gbiye lówo àwon òrìṣà Yorùbá yooku.

Bákan náà ewe, Ládélé (1980) gbà pé Ògún ló mo orí, ṣùgbón lódo Ajàlá alámò ni èdá kookan ti ń lo gbe orí tire kí ó tó máa bo sáyé. Leyin ni wí pé ní ṣe ni wón dá ori mọ yató sí ara yòókù. Oríṣi orí méji ló wà lọdọ Ajala alámo “orí rere” àti “orí búburú”. Ẹni tí ó bá yan orí búburú, òrò rè lè má téte gùn. Ṣùgbón Abímólá (1997) so pé tí olórí rere kò bá tẹpá mósé, ó le sà li ge oríire. Ti eni tí ó bá sà Yàn orí tí kò dára bá tẹ apá mósé, tó sì ń rúbo, orò rè yóò lójú tùú.

## 3.2 ÁLAYÉ ÌGBÀGBÓ YORÙBÁ NÍPA ÀYÀNMÓ

Àyànmó jé erú tàbí onà èrè je omo ènìyàn láyé, èyí tí ó se é yi padà, ṣùgbón nítorii rúdurùdu àti ìbajé ayé, ayé fúnrarè gan-an dàbí ìgbà tí wón ń fi padà. Ṣùgbón tí èyi kò ri bẹ́ẹ̀. Ayànmó jé òye tàbí agbára fún orí. Bákan-náà, wón tún ṣàlàyé àyànmo gégé bí ìpín fún orí.

Igbàgbó àwọn Yorùbá tí ó fesè ranlẹ̀ jùlo ni pé Yorùbá gbàgbé pé ipín orí fún ọmọ èdá ti wà lákosílè, ó jé ohun tí ẹ̀dá ti yàn. Èyí ni ó mú opo ọmọ Yorùbá ní ìtẹnumọ́ èyí nítorí pé wón ni igbàgbó pé gbogbo ohùn tó bá ṣele sí èdá láyé tàbí òhun ti ẹ̀dá bá ṣe láyé ti wà láyé tàbí wà lówo àkosíle láti igbà ti wọn ti búi sáyé.

Oríṣiríṣi àríyànjiyàn tí ó wà lááárín àwọn onímo ni pé njẹ́ Olódùmarè ni o yan ipín tàbí àyànmó fún èdá? Ǹjẹ́ tó bá je béè, kílódé tí ẹdá fi ní ákúnlèyàn. Eyi ni pé kí a kúnle níwájú Aṣèdá láti yan ipín tiẹ́. Wón ni Olódùmarè kò yàn fún ẹnikẹni bí kò se pé ènìyàn ni ó yàn-án fún’rare tàbí kí á ní orí rè ló yàn-án fún-un.

Àwọn onímọ̀ kan tìẹ̀ so pé níwòn ba igbà tí Olódùmarè kií ṣe aláwadà tàbí eléré ẹnìkankan, Olórun kií ṣe bii ènìyàn tí ó máa ń moo mo so èdá sínú ìsòro, gbogbo àyànmọ̀ tí a yàn láti òrun ni o dára, ohun tí oníkálùkù yan ni ó yàtò sí ara won.

Àwọn Yorùbá gbagbo pé ní àkókò ti èdá ń kúnlè láti yan ayànmó tí ó wà ní anfààní láti mò wí pé ohun tí òun fé yan kò dára, wón ní ó ní ànfààní láti yàn òmíràn.

Bákan-náà èwè, wòn ní ohun tí ó sókùnkùn sí àwa èdá ni pé, ní àsìkò tí ó fé yan àyànmó, won ò kíí so fún wa. Ojogbon Awólàlù tie sọ pé gbogbo àyànmó tí ò wà lórun ni ó pé tí wón si ti ko pé yóò dára. Ṣugbon ti ìwà èsè ayé yìí jé idènà fún-un nítorí idi èyi ni orúnmìlà ṣe je eléríí ìpín láti lè je olùrànlówó fún ènìyàn níwọ̀nba ìgbà tí wón bá to ó wá. Yorùbá gbàgbó pé Òrúnmìlà wà níbe lásìkò tí wó nn yan àyànmó, ó mo ohun gbogbo àti ètò tí ó le şe láti fi yí àyànmó padà bó sí dáadáa.

Òrìṣiriṣi nǹkan ni ó ro mọ̀ àyípadà àyànmó ṣùgbón Olódùmarè kò kan nìkan ní dandan fún àwa èdá, tó bá jé béè ohunkóhun ló ní lágbára láti yi àyànmó padà.

## 3.3 IPA TI ORÍ ŃKÓ NÍNU AYÉ ÈNÌYÀN

Ogúndá méjì ló so pé ipa ti orí ń kó nínú ayé èniyàn kò kéré. (Abimbola 1969) nínú odù yìí Orúnmìlà pé àwon irúnmolè bíi Ṣàngó, Ọya, Ogún, àti Osùn, Orúnmìlà ń bèèrè pé ta ló lè bá èdá ràjò tó jìnnà réré, tí kò ní padà leyin edá. Gbogbo won so pe nígbà tí àwọn bá ti kó òhun tí àwọn féràn tí ó si té àwọn lórùn, ní àwọn yóò dèyìn léyìn ẹ̀dá.

Òrúnmìlà pàápàá so pé òun kò lè télé èdá títí láí. Ifá wá dáhùn pé; Orí nìkan,

Ló tó alásànàn bá rókun,
Orúnmìlà ní tí babaláwo bá kú,
Won á ní e lo rufá rè dà sí kotò,
Bí Adósù Sàngó bá kú,
Wón á ní e kó ṣàngó bá kú,
Bí akápò-dsà bá ku,
Wona ni e kò sango ré dànu,
Bí akápo ọ̀sà bá kú,
Wón á ní e kó gbogbo nìkan toro.
Orúnmìlà ní nijó tí èèyàn bákú,
Ta ni won ó gbé orí rè lé?
Ifá ní orí o,
Orí nikanlótó alásásàn bá rokuru,
Bí mo bá lówó lówó,
Ori ni n ó rò fun,
Orí i mi iwo ni,

Bí mo bá bímo láyé,

Orí ni ń ó rò fún,

Orí i mi iwo ni,

Ire gbogbo tí mo bá ni láyé,

Orí ni ni ó rò fún,

Orí i mi iwo ni,

Orí pẹ̀lé,

Atètè gbéni kóòṣà.

Ẹsẹ ifá yií fi hàn wá pé ori ferè é se pàtàki sí olórí ju àwọn irúnmolè lọ. Awon ipèdè Yorùbá miíràn nípa orí túbò fi ipò pàtàki tí Yorùbá to orí si hàn. Won á máa so fún lyàwó tó bá ṣèsè ń lo sílé oko wí pé:

Móri lo, má mú ú iwà lo,

Òôjó lewà á bộ

Orí eni ní ń báni gbélé oko.

Ti wón bá rẹ̀ enikan jẹ, won a máa gba eni tí wón réjẹ ní ìmòràn pé kí ó fi onítohún sílé nítorí pé;

Orí jà joogùn,

Oogùn ló lojó kan iponjú,

Wón á tún máa ní

Orí tí a gbé wáyé ló ni ojó gbogbo

Bákan-náà tí obinrin bá fé lo di Irun orí rẹ, wón á ní, mo fé lo tún elédàá mi şe.

Ìyen ni pé ipo elédàá ni Yorùbá to ori-inú sí, tí tòde ń şe àpeerẹ rè. Yorùbá a máa pe ori wón ni oníṣe, won a sì máa béé kí ó gbè wón kúrò nínú iṣoro. Wón á ní;

Orí mi oniṣe gbàmí

Yorùbá gbé orí ga ju òrìṣà lo, idí níyì ti wón fi máà n so pé;

Orí ni à bá bo A ba f'oriṣa sile,
Nigbà tí ori ń gbéni, níbo lòrisà wà?

## 3.4 AJOSEPO ORI, OWÓ, ESÈ ÀTI IGBÀGBÓ YORÙBÁ

Àwọn Yorùbá gbàgbó wí pé yíyàn ni a máa n yan ori láti òde òrun wá. òrìṣà-ńlá ló ń dá èniyàn, ojú, imú, enu àti gbogbo ara ènìyàn. Ṣùgbọ́n Olódùmarè ló ń fún ènìyàn ní èmí. Àwọn elòmíràn ń ṣó pé Ògún ló ń ro egúngún èniyàn. Èyí tí ó dá ni lójú ni pé odò àjàlá ni a ti ń yan orí-inú. Orí inú yìí ló dúró fún àyànmó tàbí ipín àwa èdá. Ẹni ti ó bá yan orí rere láti odò àjàlá ní láti ṣorí rere láyé pàápàá jùlo bí olúwarè bá fi owo àti ẹsè ará rè ṣiṣe kún orire tí ó yàn lórun. Ení tí ó bá yan orí rere nílé Ajàlá, bó bá délé ayé tan, ó di dandan kí ó mán kólé mólé, kí ó máa fàjùlo kanta. Irú ẹni béè ló ń jèrè òtítí baba ajé.

Ẹni ti ó bá yanrí burúkú nílé Ajálá, bó ṣiṣé kò le rérè kánkan je. Irètí kan náà tó wà fún irú èniyàn béè ni kí ó máa rúbo kíkan. Ẹbọ rírú yìí ni ó máa báa kún orí burúkú tó gbé wá tí tí yóò fi tún padà so ó di déédé èyí tí ó gbé kúrò lóde orun. Nígbà náà ni eni tí ó ní orí náà yóò tó maa ri ṣe.

Ṣùgbọ́n irántí gbodo máa wà fún wà pé eni tí ó yanrí rere, àti eni tí ó yanrí burúkú, gbogbo wón ló ní láti fi owo àti ese ṣiṣe won tó donire. Nítorí náà, ori rere yíyàn lódo Ajàlá le sài sọ ènìyàn donire bi oluwa rè kò ba ṣiṣé, ori rere tí olúwa rè yàn yóò wá níbè lásán ni, kò ní so èso rere.

Ohun tí ó se pàtàki síwa ni pé, ohun tí ó lè mú orí rere so èso náà ni eso. Eni tí ó yan orí rere, ṣùgbón tí ò mú esè, agangan ń tan ara ré je lásán ni, nítorí pé ire kò ni tè é lówó. Èsè ifá kan ṣe àlàyé èyí nígbà tí ó so pé.

Òpede mo mò dé o,

Awo ẹsẹ

Ẹnìkan kìí gbimooràn

Kó yo tèsè élè.

Ko sí eni tí ó le sà irú orí tí dun yan lorun, bí rere ni tàbí búburú, àfi Orumilà nikan. Ṣùgbón bí ènìyàn bá fi owó atí èsè se ìrúbo ni igbọnràn sí oro àwon babaláwo, bó pé tító, olúwa rẹ yóò doníre.

Nǹkan mìíràn tó tún ṣe pàtàki ni “ÀYA”, èyí tí a fi ń yan doré. Èniyan nílò pré tí ó máa bá olúwarẹ gbimoràn nípa igbésí ayé olúwa rẹ. Ore yìí náà ni ó máa ń bá olúwa rè pètè pèrò nípa ojó iwájú. Èyí ni àwọn bàbá wa fi ń wí pé:

Ọ̀rẹ̀ ẹni ní ń bá ni pilè orò,

Ará ilé eni ní ń bá ni náa.

Ohun tí ó dúró fún òré nínú búré ara ènìyàn ni àyà. Bí èniyàn yan orí rere jù béè lọ, bí kò bá fi àyà yàn oré rere, imòràn olúwa rè kò ní gún.

Ese ifá orísirísi àlàyé nípa òré. Ifá so wí pé oré ju bàbá àti ìyá eni lọ, ó ju omo iyá àti ìbátan gbogbo lọ.

# ORÍ KẸRIN

## 4.0 ÌFÁÁRÀ

Gégé bí à tí mọ̀ pé ẹ̀yà Yorùbá jẹ̀ ẹ̀yà kán tí ó ní àwọn ohùn tí wón gbà gbọ nínú rẹ tí wón sì ń ṣe atókapP fún àṣà àti ìṣe wọn, àwọn ìgbàgbó wọnyí kìí ṣe ohùn tí ẹnìkan kan lè fi ọwọ yẹpẹrẹ mú tàbí kí ó fi ṣàwàdà rárá . Yorùbá bọ̀ wọn ní bí ò bá sí ohùn tó ṣe ẹ̀sẹ̀ , ẹ̀sẹ̀ kìí dédé ṣé. Nítorí ìdí èyí, lábé ìpele yìí ní a ó tí ṣe àgbéyẹ̀wò ohùn tí ó ṣe okùnfà yíyẹ àkọsẹ̀jaye ọmọ wò, béẹ̀ sìni a ó ṣe àyẹ̀wò ohùn tí ifá sọ nípa orí àti àyànmọ̀ pélú ohùn tí ìwà ní í ṣe pẹ̀lú orí.

## 4.1 ÌGBÀGBỌ̀ YORÙBÁ NÍPA YÍYẸ ÀKỌSÈJAYE WÒ

Ọkàn pàtàkì lára ìgbàgbọ̀ Yorùbá tàbí àwọn babańlá wà ní láti yẹ àkọsèjaye ọmọ tí wọn bá bí wò. Ìdí ìgbàgbọ̀ wọn ní pé ó lẹ́wu tí wọn kò bá ṣe é fún irú ọmọ béè.

Yíyẹ àkọsèjaye tàbí ìpín ọmọ wo ni won fi ń mọ irú ohùn tí orí ọmọ náà rómọ̀ láti ṣe àti láti jẹ. Bákan náà, àwọn ìgbésẹ tí ó léwu fún ọmọ náà yálà nígbà èwe tàbí lẹ́yìn tí ó bá dàgbà tí ó ti tójúbọ. Nínú ìgbàgbọ wọn náà ni pé láì yẹ àkọsèjaye ọmọ wò, kò lè jẹ́ kí àwọn mọ ohùn tí ó yẹ fún àwọn láti ṣe fún ọmọ náà àsìkò tí ó wà ní kékeré tàbí lásìkò ó ti dàgbà.

Wọn tún gbàgbé pé ó ní àwọn ìgbésẹ kan tó yẹ kí òbí gbé ní kété tí wọn bá bí ọmọ yàtọ sí ọrọ ìdílé tí bàbá tàbí ìyá ọmọ náà. Bí ó tilè jẹ pe kìí ṣe gbogbo ìdílé sùgbón a ní àwọn tí wọn ní.

Nípasẹ̀ yíyẹ àkọsèjaye ọmọ wò ni Yorùbá fí fi ìdí rè múlẹ pé èèwọ̀ ni láti fi abẹ kan orí àwọn ọmọ kan nígbà tí a bá bí wọn láìpé pé ọrọ ìdílé wọn ni ó kọkọ ṣáájú tàbí kí à fá Irun orí béè ní ọ̀nà tí Ẹlẹ́dàá wọn r'omo. Àpẹẹrẹ irú àwọn ọmọ báyìí ni (

Dàda). Yorùbá gbàgbó pé bí a kò bá yẹ àkọsèjaye irú àwọn ọmọ báyìí wò, ó ṣeéṣe kí a má mọ irú ohùn tí Ẹlẹdàá wọn r'omo ati6 ohùn tí Ẹlẹdàá wọn kò r'omo.

ỌPỌ òbí ló máa ń yan iṣẹ tàbí olólùfe fún ọmọ wọn, bí ó tilè jé pé kò sí ohùn tí ó burú níbè, ṣùgbón ṣé ó bá àyànmo tàbí àkọsèjaye ọmọ náà mú tàbí ṣe kádàrá olólùfe méjì náà bára wọn mu. Nínú ìwádìí àwọn onímọ̀ wọn fi ìdí rẹ múlẹ pé kò sí láìfi tàbí ohùn tí ó burú níbè níbè láti yẹ àkọsèjaye ọmọ wò, béè sìni kò lòdì sí ẹsìn Kankan. Wọn fi ẹsẹ òrò yìí múlẹ nínú ìtàn àwọn ọmọ Israẹli ìgbaanì, wọn wí pé àwọn náà máà ń ṣe ìwádìí lórí ọmọ tuntun tí wọn bá ṣẹ̀ṣẹ̀ bí èyí tí ó fi ẹsẹ rinlẹ gẹgẹ bí ìtàn àti ẹ̀sìn ṣe sọ pé Ọlọ́run fi hàn wọn pé kí wọn má ṣe fi abẹ kan orí sámúsìnì (Samson) èyí tí a lè fi wé Dàda nílé Yorùbá, béè náà sìni Sàmúẹlì.

Tí a bá wo àwọn ohùn tí a tí sọ lókè wọnyí, a ó rí pé ìran Yorùbá kìí dédé gbé ìgbésẹ kankan lórí ìgbàgbọ wọn sì ohunkóhun.

## 4.2 OHÙN ẸNU IFÁ NÍPA ORÍ ÀTI ÀYÀNMỌ

Yorùbá gbàgbọ pé yìyàn ni a máa ń yan orí láti òde ọ̀run wá.

Òrìsà ńlà ló ń dá ènìyàn ní ìbámu pẹ̀lú gbogbo ẹ̀yà, sùgbón Olódùmarè ló ń fún ènìyàn ní ẹ̀mí. Àwọn ẹlòmíràn ń sọ pé Ògún ló ń rọ egungun fún ènìyàn , sùgbón èyí tí ó dájú ní pé ọ̀dọ̀ Àjàlá ní a ti ń yan orí inú yìí ló dúró fún ayànmọ tàbí ìpín àwa ẹ̀dá.

Oríṣiríṣi irú ifá ní ó ti sọ̀rọ̀ nípa orí tàbí bí àwọn ènìyàn ṣe ń yan orí láti ọ̀run. "Odù Èjì -ogbè "sọ àti ipa pàtàkì tí orí ń kó nínú ìgbésí ayé ènìyàn pàápàá jùlọ nínú ìjọ ilẹ̀ Yorùbá . Ẹsẹ ifá náà dá lórí babaláwo kan tí ó fé ni ire gbogbo tí ó wá lọ fi ẹjọ sún Ọ̀rúnmìlà , ó wí pé gbogbo ire ni òun ń wá , Ọ̀rúnmìlà ní kí akápò ó lọ sọ fún Èsù ẹní tí í ṣe àláṣẹ fún gbogbo àwọn òrìṣà. Nígbà tí babaláwo náà dé ọ̀dọ̀ Èṣù, ó sọ fún-un pé gbogbo ohùn tí ń dun babaláwo náà kò dun ifá, Èṣù wá gbà à ní í ìmọ̀ràn wí pé kí ó lọ rọ gbogbo ohun tó ń fé fún orí rẹ .

Nígbà tí akápò ṣe béè tán ní gbogbo nnkan tí ń fé tó wá tẹ̀ é lówó. Ó wá ń jó ń yọ̀ , ó ní;

Ǹjè ohun gbogbo tó bá ń dùn kì

N ó máa rò dórí ì mi

Orí ẹni ni alágbọ̀rọ̀dùn ẹni

Ìwọ lalàgbọ̀rọ̀dùn.

Pàtàkì ohun tí ẹsẹ ifá yìí ń sọ wa ni pé kò sí òrìṣà tó le dáni gbè lẹyìn orí ẹni. Nítorí náà ohunkóhun tó ń dùn wà kí à kókó fi lọ orí ẹni , ki orí ẹni ó fi ọwọ síi, kí ó tó di wí pé àwọn òòsà ṣe nǹkan náà fún òun. Orí oníkálukú ni òrìṣà rè ti kò lè dà, tí ó sì ń gba ọ̀ràn rè yẹ̀wò.

Ìdí nìyí tí ẹsẹ ifá mìíràn fi sọ wí pé;

Orí pẹ̀lé

Atèté níran

Atèté gbé ní kòòṣà

Kò sóòṣà tíì dá ni gbè

Lẹyìn orí ẹní

Bákan náà, "ìwòrì méjì" náà kò sàì ménu ba ọ̀rọ̀ orí. Nínú ẹsẹ ifá rè , ò wí pé, ìpín tàbí orí oníkálukú nìkan ló lè gbè è. Bí Òòsà kan tilẹ fé gbe èniyàn , tí orí olúwarẹ̀ kò bá lówó síi, kò ní ṣe é ṣe . Irú àpẹẹrẹ báyìí ní ó mú pe " akápò tó lọ fi ẹjọ Ọ̀rúnmìlà sùn lọdọ Olódùmarè, ifá ní òun sa gbogbo ipá òun fún akápò , sùgbón, ìpín akápò ni kò gbà. Èyí fi yé wa pé orí ẹni ló máa ń tọrọ nǹkan náà . Ẹsẹ ifá náà lọ báyìí.

Ọwọ èwe ò tó pẹpẹ.

Tàgbàlabà ò wọ kèrègbè,

Iṣẹ èwe bẹ àgbà,

Kí ó ma6 ṣe kọ̀ wọn,

Gbogbo wa ni nísẹ a jọ ń bẹ ra wa,

A díá fún Ọ̀rúnmìlà ,

Èyí tí akápò o rè,

Ó pè è lèjọ lọdọ Olódùmarè,

Olódùmarè wá ránṣẹ sí Ọrúnmìlà,

Pé kí ó wá sọ ìdí náà,

Tí kò fi gbe akápò rè,

Nígbà tí Ọrúnmìlà dé iwájú Olódùmarè,

Ó ní òun sa gbogbo agbára òun,

Nígbà náà ni ọ̀rọ̀ náà,

Tó wá yé Olódùmarè yekeyeke,

Inú-un rè sì dùn wí pé,

Òun kò dá ẹjó ẹkùn kan.

Òsá Méjì náà ọ̀ sàì mẹnuba pàtàkì orí. Ẹsẹ̀ ifá yìí ń jé kí à mọ̀ pé kìí ṣe gbogbo ènìyàn ló Yan orí owó tàbí ọlá . Nítorí náà , kìí ṣe gbogbo ènìyàn ni a ó fí pósí sin. Ẹlòmíràn à kú sígbó, ẹlòmíràn yóò bá ogun lọ, ẹlòmíràn yóò si kú gégé bí akúsèé tí yóò fi jé pé àwon ènìyàn rẹ kò ní fi pósí sin- ín.

Èyí ni ìtumọ̀ ọ̀rọ̀ tí ifá so wípé;

Bí ó bá ṣe wí pé,

Gbogbo ènìyàn níí sun pósí,

Ìrókò gbogbo ìbá tí tán nígbó.

Ọrúnmìlà tún tẹ̀síwájú nínú odù ifá yìí kan náà pé àwa ẹ̀dá kìí fé tètè gba ìpín tí a Yàn lọdọ Olódùmarè. Nítorí náà , ó máa jòwèrè bóyá a lè rí ìpín rere kó. Ṣùgbón níwòn ìgbà tí ó tí jé wí pé àyànmọ kò ṣe é yàrá yípadà, ìyọrísí owere ọ̀pọ̀ ènìyàn kìí já sí rere rárá. Ifá sọ̀rọ̀ kíkorò níhìn-ín pẹlú ìgboyà. Ọ ní;.

Òwèrè là ń jà,

Gbogbo wa,

Òwèrè là ń jà,

Ẹni tó yanrí rere kò wọpọ,

Ò wèrè là ń jà,

Gbogbo wa.

Ní àkọtán, Òsá méjì tún tẹ̀síwájú pẹ̀;

Orí burúkú kìí wú tùúlù,

A kìí dá ẹsẹ asiwèrè mọ̀ lọnà,

A kìí morí olóyè láwùjọ,

A díá fún móbówù,

Tíí ṣe obìnrin ògún,

Orí tí ó jọba lóba

Ẹnìkan ò mọ̀,

Kí tọkọtaya ó para wọn,

Ní wèrè mọ̀,

Orí tí ó jọba lóla,

Ẹnìkan ò mọ̀.

Ohun tí Ifá yìí ń gbìyànjú láti sọ ni pé kò sí ẹni tó dá orí burúkú mọ̀ pẹlu ojú lásán gégé bí ó tí jẹ́ wí pé ẹnìkan kò lè dá ẹ̀ṣẹ̀ asiwèrè mọ̀ lòjù-ọ̀nà, tí kó sì lè mọ òrí Olóyè láwùjọ. Ifá wá sọ pé kí tọkọtaya ó má ṣe bú ara wọn ní èébú burúkú mi nitori pé a kò mo ẹni tí ó di ọlọlá nínú wọn. Ifá wá parí ọ̀rọ̀ rẹ̀ pẹlú pàtàkì, Ó ni.

Orí tí ó jọba lọla,

Ẹnìkan ò mọ̀.

Ìtumò ohùn ti ifá ń wí níhìn-ín ni pé a kò gbọdọ̀ sọ pé ẹnìkan kò lè nǹkan kan láyé nítorì pé akọ mọ irú orí tí ẹnìkan mú wáyé. A kò gbọdọ̀ ṣe láyé yìí nítorí pé Ọ̀rúnmìlà nìkan ló Mọ olórí rere.

## 4.3. ÌGBÀGBÓ YORÙBÁ NÍNU ÌWÀ GẸ́GẸ́ BÍ IFÁ ṢE WÍ

Gègé bí Yorùbá ṣe gbàgbó nínú orí, béè náà ni wón ṣe gbàgbó nínú ìwà. Èyí ni pé wọn gbà ìwà gbọ́. Orí jẹ́ ohùn tí ènìyàn ń mú wa láti orun, ṣùgbón oníkálukú ló máa ń yan iwa tirè láyé. Oríṣi méjì ni iwa ti ó wà láyé, ìwà rere ati ìwà búburú. Èyí tí ó bá wù oníkálukú ló lè yan níbè. Ṣùgbón ẹni tó bá wí pé ìwà búburu ni òun yóò máa wù níwà, kí ó mọ dájú pé òun lè rí ìjà àwọn ará òrun pelu, nítorí pé àwọn irúnm ọlẹ̀  ka irú ènìyàn béè sì òbàyéjé.

Ohun tí Yorùbá gbàgbó ni wí pé bí eniyan tilẹ Yàn orí réré, tí ó sí fọwọ́ àtẹtẹ̀ ṣiṣẹ́ láyé, bí kò bá ni ìwà rere, ati òrun rẹ̀ kò lè dára. Olódùmarè àti àwọn òrìṣà ń fi

ki awa ki máa wuwa réré sí ọmọlakeji wa. Ẹni tí ó bá ní ìwà búburú, tí ó sí ń wù ù níwà bíi ole- jìgá, ilẹ̀-dìdà, àti àwọn òrìṣà ló máa ń fi ìyà jẹ, irú ènìyàn bẹ́ẹ̀. Fún àpẹẹrẹ. Ṣàngó ló máa ń pa ole ati èké. Eégún ati ile ló sì máa ń yẹjú áwọn ọdàlẹ.

Iwa ti a ń wí yìí, Ifá sọ fún wa pé obìnrin ni, àti pé àyà Ọ̀rúnmìlà ni. Nígbà tí ìwà ba ohùn ti ó ń wù kó lẹgbẹ mọ́, ni Ọ̀rúnmìlà bá kó ìwà àyà rẹ sílẹ. Ni ìwà ba bínú lọ sí ilé Olódùmarè. Ṣe ọmọ Olódùmarè sì ni ìwà nítorí pé òun ní í ṣe àkọ́bí 'sùúrù ni baba iwa'. Nígbà tí ayé Orúnmìlà wa wa doríkodà nítorí pé ìwà sọnù, ló bá múra láti wá Obìnrin rẹ lọ. Ṣé wọn ní;

Bí ìwà bá ni ènìyàn,

Ẹ̀yin ò mọ pé,

Ayé olúwarẹ lónù.

Béè ni Orúnmìlà bó sínú ẹ̀kù Eégún, ó bẹ̀rẹ̀ sí ní sa obìnrin rẹ kaakiri. Ó wà á délé Alárá, Èjì Ọ̀sà, Ọmọ amúrin kan dọ́gbọ̀n agogo.

Ó wà a ṣe ilé Ọ̀wàràngàn àga, Amọ̀nà èdè, Onígúrú, Àgùn fi ọwọ làbá owó tetéété, O wá a delẹ ọjà mérìndínlógún, ṣùgbọ́n kò tíì. Ló bá gbóna òde ọ̀run lọ. Ìwà ki Ọ̀rúnmìlà nìlọ̀ pé kí ó máa fi ọwọ́ rẹ tún ìwà ara rẹ̀ ṣe.

Ìtàn yìí fi ye wà pé ẹgbin ati iwọsi ń bẹ nibi ki a máa, wù, ìwà rere, ṣùgbón a ní láti máa tọjú ìwà ara ẹni, a kò gbọdọ̀ jẹ́ kí ó ṣí ló nile ẹni. Ohunkóhun tí ènìyàn bá ẹgbẹ àti òtúbá tí. Ọ́ ní;

B'áa lówó,

Bá à lówó,

Ọwó olówó ni,

Ìwà, ìwà là ń wò,

Ìwà,

Ọmọ la bí táà níwà,

Ìwà, ìwà là ń wà ọ,

Ìwà.

Diẹ nínú àwọn ìwà rere tí àwọn òrìṣà ati àwọn ará òrun ní fún ki á màá wù ni kí á máa sọ òtítọ kí á sì máa ní sùúrù. Ọ́ ní;

Ìbínú kò da nǹkan kan fún ní,

Sùúrù baba ìwà,

Àgbà tó ní sùúrù,

A díá fún Ọ̀rúnmìlà

Ifá ń ṣawo lọ iwò àtẹ,

Ìyá ti Ifá jẹ ní wòó,

Lò bákọ, ló bábo.

Nipa kí á máa sọ òtítọ, Ọ̀rúnmìlà wí báyìí pé;

O le gbé ni jùkà o,

Mo ló o le gbé ni jùkà,

Òtítọ mọ ló lè gbé ni jùkà.

Diẹ nínú àwọn ìwà búburú tí àwọn òrìṣà àti àwọn ará ọrun ò fẹ́ ilẹ̀ dídá, èké, àti olè jíjà. Ó ní:

Ọ̀fófó níí pẹrú,

Ẹpé a sì polẹ́,

Ilẹ̀ dídá níí lè,

Alájọbí níí pé,

Alájọbí níí pa ènìyàn tó ṣebi,

A jọ gbórí ilẹ̀ a jeki,

A jọ gbórí ilẹ̀ a jẹja,

A jọ gbórí ilẹ̀ a jẹ kòkò ìgbín,

Àṣẹ dọwọ́ ilẹ̀ a jọ mu.

## ORI KARÚN -ÚN

## 5.0 ÌṢONÌSÓKÌ

A kìí mọ̀ ọ̀nà tó títí kí a débi ònà gbé pẹ̀kun, bí ìtọ̀ná bá sú ni tàbí bí a bá débi á ń rẹ̀, ó di dandan ki a dẹ́kun itónà fún sáà náà. A ti gbiyànjú láti se àlàyé tí ó lóórín lórí ojú ìwòye àwọn Yorùbá nípa orí inú àti ìpín tí èniyan yàn láti òde ìṣàlú-orun, a si ti so òpòlopò àlàyé tí a si fi oriṣiírìṣi isé àwọn aṣáájú ṣe ègbè lẹ́yin ìwòye wa gbogbo.

Ní orí karùn-ún yìí, a ó gbìyànjú láti ṣe ìsoníṣókí àwọn ohun tí a yèwò ni orí kìn-ín-ni dé orí kẹrin ìṣẹ́ yìí a ó si tún wo ibi tí a fi ẹnu ọ̀rọ̀ jóná si lórí kókó kọ̀ọ̀kan.

## 5.1 ÀGBÁLỌGBÁBỌ̀

Mélòó la ó ká nínú eyin Adépèlé? Tínú orùn tóde òjò, egbeélégbé ni ń lábẹ̀ èrigì tí kò ta síta. A ti se àlàyé loríṣàiri ṣi nínú iṣé wa, pàápàá àwọn àlàyé tí ó ní á ṣe pèlú ìgbàgbó àwọn Yorùbá nípa orí inú àti ìpín tí ènìyàn mú wá sílé ayé. Àwọn ibi ti a sì fi ẹnu òrò jóná sí nì.

Yorùbá ní igbàgbó wí pé orí méjì ni èniyàn ń gbé wá sí ilé ayé, àwon orí náà si ní orí òde àti orí inú, Orí inú yì ílé jé orí rere ó sìlè je orí burúkú. Irú ori ti èniyàn bá yàn lórun ni yóò so àyàmó tí yòó wá mú ṣẹ láyé.

Ìgbàgbọ́ mìíràn tí àwọn Yorùbá na ni wí pé Ọ̀rúnmìlà bara Agbonmìrègún ni elérií tí ó wà pèlú Elédùmarè nígbà ti oníkálúkú n yan ipín re. Èyí ni ó sì fà á tí ó fi jẹ́ wí pé Òrúnmìlà nìkan ni Irúnmolè tí o lè mo irú ìpín tí òun mú wáyé àti àwọn nǹkan tí ó rọ̀ mọ́-ọn.

Ohun mìíràn tí a tún sòrò bá nínú iṣe yìí ni orí bíbo. Orí bíbọ wúlò gidigidi. Yorùbá ń ṣe èyí ká orí wọn lè gbè wọ́n àti tu àyàmó tàbí ipín wọn lè di mímúṣẹ kankan.

Síwájú síi, a ko ṣai wo ohun tí ìgbàgbọ́ jé láàárín àwọn Yorùbá. A jékí ó di mímọ wí pé igbàgbó ki í ṣe ohun àjèji rárá láàárín àwọn Yorùbá. Láti ibèrèpèpè ni ìgbàgbó wọn tí ro mó nǹkan kàn tàbí òmìí. Pàápàá jùlo nípa ohunkóhun tí ó báti je mó orò ẹ̀sin àti ibágbépò èdá.

Ní òde òní, tí ẹ̀sin ìgbàgbó nínú kírísíti àti èsin isiláámù tifesè mule dáadáa, mọ irú àyànmó tí èniyàn gbé wáyé ti tútù lókan àwọn ọmọ káááro-o-o-jíire. Àwọn tó náání ẹ̀sin abáláyé kò tó nǹkan, ariwo Jésù àti Mùómódù ni gbogbo won ń pariwo kiri, Ijoba pàápàá kò náání èsin ibílé rárá, ésin àjèjini wón di ro mó gboingboin bí ó tí wùn kí ó rí a şi rí àwon iwònba dié rébété tí ó sì náání èsin ibílè ti won si gbàgbó nínú yíye àyanmọ́ wò, wón sì ń kà á sí ojúṣe títí di òní olónií. A kò sài wo àwon àsopo tí ó wá láàárin orí àti àwọn èyà ara yòókù, ohun tí a sì rí ni wí pé àjo èyá ara kò lè pé bí wón bá fé ti orí kú láwujo wọn.

Pẹ̀lú gbogbo ohun tí a yẹ̀wọ̀ nínú iṣé yìí, láisí àníàní, iṣẹ̀ àpilẹ́kọyìí yóò wúló púpo púpò fún àwọn túlé tí ó bá fé se ìwádií nípa orí-inú àti ìpín àwa edá, yóò si tún wúlò fún enikéni tí ó bá fé lò ó fún iṣẹ́ àṣekágbá àti àwọn tì ó bá fé kà á fún imọ̀ níní.

# AKOJOPO ORÚKỌ IWÉ


Abímbọ́lá, Wánde (1975) Sixteen Great Poems of Ifá: Hiamey, UNESCO

Abímbọ́lá, Wánde (1975) Àwọn ojú-odù mẹ́rìndínlògún, Ìbàdàn University Press limited

Abímbọ́lá, Wánde (2006) Ìjìnlẹ̀ ohùn ẹnu Ifá (Apákìn-in-ni) Ìbàdàn University Press limited

Adéoyè C.L (1980) Aṣà àti Ìṣe Yorùbá, Ìbàdàn University Press Limited

Adéríbigbé, S. O. (ẹ̀òòò). Ewì Alohùn Yorùbá, Ìbàdàn University Press Limited

Abímbọ́lá, Wánde (1977). Awon Oju Odu Merindinlogun. London: Oxford University Press.

Àjànàkú, Fagbemi (1970). Orí, Ìpín àti Kádàrá Apakeji. A paper delivered at the Conference of Ègbé Ìjinle Yoruba, Lagos.

Awolalu, J and Dopamu, P.A. (1991). Àwọn Ẹsin Ìbílè Ìwọ̀-oòrùn Áfíríkà. Ìbàdàn: NK .

Idowu, Bólájí (1975). Èsìn Ìbílè Áfíríkà – Itumọ.

London: S.C.M. Press.  (1996) ìgbàgbọ́ Yorùbá nínu Olórun. Èkó: Longman.

Tregbons, J.S. (1970). Àwọn Ẹsin Áfíríkà àti Imoye.

Laude, Jean (1973). Ìlànà Bíbọ Orí ní Ilé Adúláwọ̀,

U.P.E. Iṣẹ ọna àti Ọnà (1997). Igbimọ Iwadi Ẹkọ Naijiria.

Gbadegesin S: Eniyan; Èèyàn Yorùbá. Ṣatunkọ nipasẹ PH Coetzee ati A.P Roux York, 1998) P.144

Idowu E.B.: Olódùmarè: Olórun nínú ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá.

Adeoye C.L. 1971: Ẹdá Ọmọ Odùduwà.

Ali, Ameer, 1974, Èmí Islam,.

Awolalu J. O. and P. Adelumo Dọpamu, (2005), Ẹsin Ibile Ìwọ̀-oòrùn Áfíríkà, Atunwo ed., Macmillan Nigeria Publishers Limited, Nigeria, p. 184.

Brand, Leonard, (1997), Ìgbàgbọ́, Idi, & Itan Aye, Andrews University Press, Berrein Springs MI, p. 77.

Cox, James, 1996, Expressing the Sacred, University of Zimbabwe Publications, Harare, p. 137.

Kosslyn, Stephen M. and Robin S. Rosenberg., (2001), Ẹkọ nípa ìṣẹ̀dá èniyàn, Ọpọlọ àti Ojú, Allyn ati Bacon, Needham Heights, p. 77.

Muhammad, S. O., (2007), "Ète Ìṣẹ̀dá", nínú The Scholar, vol 1 No 1.

Opeloye, M. O., (1988), "Àyànmọ́ àti igbagbo nínú Bíbélì àti Kùránì: Ìdánwò Àfiwé" ní Orita, XX/I, June, p. 26.

Redmond, W. A., 2007 "Wiwo Awọn Ẹkọ nípa Ifẹ ati ori" ti Akeko Microsoft.

Satre, Jean- Paul, 1956, Jíjẹ Ènìyàn Pàtàkì Nípa Orí, Methuen and Co. Ltd., New York, p. 18.